# FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION

# Accelerated Basic Education Curriculum
# Yoruba Language
# (Level 3: Stage 1 - 3)

NIGERIAN EDUCATIONAL RESEARCH AND DEVELOPMENT COUNCIL (NERDC)

**Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC)**

**Headquarters**: Lokoja-Kaduna Road, Sheda, PMB 91, Abuja, Nigeria
Phone: (09) 8822202, 8822204, Fax (09) 8821047

e-mail: info@nerdc.gov.ng

Website: www.nerdc.gov.ng

## NERDC Zonal Offices:

| | |
|---|---|
| **South-East:** | Old SUBEB Building, Waterworks Road, Abakaliki, Ebonyi State |
| **South-South**: | 2nd Floor, Federal Secretariat Building, Calabar, Cross River State |
| **North-East:** | Yobe State Government Secretariat, Opposite Government Lodge, Bukar Ibrahim, Phase 1. |
| **North West:** | GP 109, State Road, Opposite Kano State High Court, Kano, Kano State |
| **South-West:** | Lagos Annex Office, 3, Jibowu Street, Yaba, Lagos |
| **North-Central:** | 3rd Floor, Rm 313 - 315, Federal Secretariat Complex, Minna, Niger State. |

## NERDC State Offices:

| | |
|---|---|
| **Anambra State:** | NERDC State Office, Post Primary School Service Commission, Awk, Anambra State. |
| **Katsina State:** | NERDC State Office, Education Resource Centre's/ERC/Building, Muhammad Dikko Road, Opposite Katsina College, Katsina/KCK/Katsina, Katsina State. |

## Foreword

One of the targets set out by the Federal Government of Nigeria under the current dispensation is the eradication of the menace of out-of-school children that has bedeviled the country since the past three decades. This target area of concern formed one of the 10 pillars of the Ministerial Strategic Plan (2016 -2019) which have metamorphosed into the Ministerial Strategic Plan (2018 -2022). The effort asserted in this direction, is in line with the Constitution of the Federal Republic of Nigeria, which recognizes education as a fundamental right of every child, irrespective of ethnic background, social-economic status, religious affiliation and family background.

One of our turnaround strategies, as outlined in the Ministerial Strategic Plan, is to create opportunities for the education of all children and youths, who for one reason or the other, are out of school. These children, who are found in many parts of Nigeria, constitute about 5% of the world's population of Out-of-School children.

The turnaround strategies were based on identified gaps and challenges in the education sector. One obvious gap identified was the lack of well-thought educational programme that specifically addresses the peculiarities of overage children who are not in school. The Accelerated Basic Education Programme (ABEP) is therefore a step taken towards filling the identified gap. Aside from addressing our domestic situation, the programme is in line with global best practices.

The specific goal of the Programme is to mop-up (or reduce to the barest minimum) and bring back to school the large number of overage and out-of-school children who are disadvantaged, marginalized and affected by crises, disasters or other socio-economic factors.

I am therefore pleased to note that the Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC) has taken this step towards the provision of the curriculum to drive the ABEP. I congratulate NERDC and her partners for successfully completing the development of the Accelerated Basic Education Curriculum for the Implementation of the Accelerated Basic Education Programme in Nigeria. I wish to particularly thank Plan International and Save the Children International for supporting the development of the curriculum under the European Union funded project: The EU Response, Early Recovery and Resilience in Borno State: Education Component. I also acknowledge the contributions of all experts who worked hard in the development of the curriculum. The curriculum is flexible and provides learning options and pathways for learners.

It is therefore my pleasure to present the curriculum to all Nigerians and our foreign partners for the education of out-of-school children under the accelerated education programme.

My utmost hope is that the effective use of the curriculum will bring about our desired aim of providing quality basic education to all Nigerian children irrespective of the circumstances surrounding their existence.

**ADAMU ADAMU**
**Honourable Minister of Education**

## Preface

Nigeria, in the recent past, has been rated as one of the countries in the world with a huge population of out-of-school children and youths. The situation became worsened by the escalation of insurgency in the northeast leading to closure of many schools and the displacement of huge number persons including children and adolescents. Credible sources have it that many schools in the northeast states were closed from November 2014 to June 2015. By August 2017, an estimated 57% of schools were still closed in Borno.

Although many of the schools have been reopened, a high percentage of children are yet to return to school due to poverty and other socio-economic factors. There are also pockets of attack, psychosocial factors that affect human instability including where to start education again, having been out of school for many years (up to 10 years, in some instances).

Further, in the recent times, there have been widespread happenings, across the country, that have led to long term disruption of the educational pursuits of children and youths. These children and youths, in most instances, are either overage to continue schooling from where they stopped or are overage to start schooling from the foundation class (Primary 1). Incidentally, this group of children are found in many parts of the country.

Addressing this situation required the articulation of a special form of educational programme that will meet the peculiar circumstance of these children in this category. Whereas pockets of efforts have been made towards addressing the challenge, Nigeria lacks a strategically designed educational programme and curriculum standards that suits the peculiarities of children in this category. Understandably, some non-governmental organizations have attempted to provide some interventions in this regard but these they had done without a nationally established framework and curriculum standards.

Importantly, the Ministerial Strategy Plan (2018- 2022) had clearly identified containing the menace of out-of-school children as one of the 10 pillars of the programmes targeted at bringing about change the Nigerian education sector.
The above scenario informed the need for the development of a National Accelerated Education Curriculum with the overarching objective of providing a catchup educational programme suitable for the educational needs of out-of-school children, and in the process mainstream them to formal school programme or provide them with alternative career path through enrolment into vocational training centres, after completing basic education. The intention to develop the curriculum arose also because of the need to provide a national curriculum standard that can be used in all states of Nigeria, where there are such peculiarities.

The Nigeria Accelerated Education Programme (NAEP) specifically targets out-of-school children between ages 10 and 18 who were in school but had their education interrupted and are overage to continue schooling from where they stopped and; those who have never been to school and are overage to start formal education from the foundation class (Primary 1). The NAEP is structured into 3 Levels as exemplified below:

- Level 1 (Stage 1 -3) to cover the curriculum contents of Primary 1 – 3
- Level 2 (Stage 1 -3) to cover the curriculum contents of Primary 4 – 6
- Level 3 (Stage 1 – 3) to cover the curriculum contents of JS 1 -3.

Each level will run for one academic year of 3 terms, similar to the regular school programme but with a flexible timetable in learner-friendly centres. The structure is further explained in the table below:

| Level | Target group |
| --- | --- |
| Level 1 | • Those who have never been to school aged 10 and above |
| Level 2 | • Those who have been to school up to primary 2 or 3 but dropped out due to one reason or the other. |
| Level 3 | • Those who have been to school up to primary 5 or 6 but dropped out due to one reason or the other. |

Five subjects were selected for the implementation of the programme. These are: English Studies, Mathematics, Basic Science and Technology, Nigerian History and Values and one Nigerian Language (Hausa, Igbo and Yoruba, in the interim).

The development of the Accelerated Basic Education Curriculum involved a systematic procedure in which the 9-Year Basic Education Curriculum (for the selected subjects) was condensed into a 3-Year accelerated basic education curriculum without compromising the quality.

NERDC's four-stage approach to curriculum development was adopted in the process. These are:

i. Planning, which involves concepts and strategy formulation,
ii. Writing (crafting) of the initial draft of the curriculum document;
iii. Critique of the draft curriculum document; and
iv. Editorial and finalization of the curriculum document.

Teacher's Guide, with detailed and well sequenced contents, instructional strategies and assessment procedures is also developed to strengthen teachers' capabilities to effectively teach the curriculum.

It is my delight to acknowledge the role played by Plan International and Save the Children International in the development of the curriculum under the European Union funded project: The EU Response, Early Recovery and Resilience in Borno State: Education Component.

My appreciation also goes to all our resource persons for their efforts, expertise and commitment to the success of the project. It is my deepest conviction that the use of this curriculum will be of immense benefit to the nation in the bid to addressing the problem of out-of-school children in Nigeria.

**PROF. ISMAIL JUNAIDU**
**Executive Secretary, NERDC**

## Introduction

The Accelerated Basic Education Programme (ABEP) is a catchup education programme meant to take care of the educational needs of overage children and youths between the age 10 and 18 who for certain reasons could not enroll into regular school or had their educational programmes interrupted. The Philosophy for ABEP, like the overall philosophy of Nigeria education; is to develop the individual into a sound and effective citizen and the provision of equal opportunities for the acquisition of appropriate levels of literacy, numeracy, manipulative, communicative and life-skills; as well as the ethical, moral, security and civic values needed for laying a solid foundation for life-long learning. On a more specific note, the ABEP is designed to mop-up (or reduce to the barest minimum) and bring back to school the large number of out-of-school children spread across many parts of Nigeria. The programme targets two categories of these children. These are:

- Children and youths whose education programme were interrupted and are overage to continue schooling from where they stopped.
- Children and youths who have never been to school and are overage to start formal education from the foundation class (Primary 1).

The ABEP, which is unique in all its ramifications, is to be implemented in 3-Levels comprising:

- Level 1 equivalent of Primary 1 - 3
- Level 2 equivalent of Primary 4 - 6
- Level 3 equivalent of JS 1- 3

In each of these levels, learners are expected to acquire basic education competencies equivalent to their mates in the regular school programme.

Given the uniqueness of the programme, it became imperative to redesign and condense the 9-Basic Education Curriculum in such a manner as to meet the peculiarities and needs of the intended beneficiaries of ABEP without compromising quality. Thus, the Accelerated Basic Education Curriculum (ABEC) is developed to provide the recipients unique learning experiences that will enable them to acquire basic knowledge, skills and competencies sufficient for mainstreaming and coping with the curriculum contents in the formal school system.

In this wise, the Yoruba Language Curriculum for ABEP is prepared to help the recipients:

1. develop reading skills in the language as foundation for early grade learning;
2. acquire the rudiments of the language as expected medium of instruction at the early grade.
3. cultivate the skills for effective interaction in the community; and
4. acquire basic cultural values, respect for elders and other people's views as a basis for interaction with members of their immediate community.

The thematic approach was adopted in the selection of the contents and learning experiences. The curriculum has further been scoped and sequenced into lesson topics for ease of implementation at the ABEP learning centres.

For the purpose of implementation, 3 hours a week has been dedicated to the teaching and learning of Yoruba Language Curriculum contents, just as other Nigerian languages. Thus, Yoruba Language shall be taught 3 times a week in ABEP learning centres.

Teacher's Guide has also been developed to further support the effective implementation of the curriculum by both teachers and policy makers. It is therefore recommended that the curriculum be implemented with due reference to the teacher's guide. Finally, it is envisaged that education managers, teachers, Development Partners and other stakeholders will provide the necessary infrastructure and support required for the actualization of the objectives of the curriculum.

**Dr. Garba D. Gandu**
Director, Curriculum Development Centre, NERDC

## TABLE OF CONTENTS


| | | Page |
|---|---|---|
| **Foreword** | | **iv** |
| **Preface** | | **v** |
| **Introduction** | | **vii** |
| **STAGE 1** | | |
| **KÓKÓ Ọ̀RỌ̀** | **Topics** | **Page** |
| Idánmọ́rán, ọ̀rọ̀ èdè àti àkàyé | • Àsọtẹ́lẹ̀ ìtàn ọlọ́rọ̀ geere tàbí eré oníṣe tí wọ́n wò | 1 |
| | • Ọjọ́ tó wà nínú èdè yorùbá | 1 |
| | • Èdè àmúlò: ìkíni | 2 |
| Èdè - ọ̀rọ̀ lámèyítọ́ lórí lítíréṣọ̀ | • Àkànlò èdè | 3 |
| | • Òwe | 3 |
| | • Ewì ìwòyí àti ìdàgbàsókè àwùjọ (sísọ- ewì ìwòyí àti ìdàgbàsókè àwùjọ) | 3 |
| | • Kíka eré oníṣe (siso-eré oníṣe/ onítàn) | 4 |
| Ìtàn ọlọ́rọ̀ geere (ohun tí ìtàn ọlọ́rọ̀ geere jẹ́) | • Ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere | 5 |
| Ìṣọwọ́kọ̀wé<br>Èrò nípa ìṣọwọ́kọ̀wé | • Ìtẹ̀síwájú lórí ìfàmìsí 1 | 6 |
| | • Ìtẹ̀síwájú lórí sípẹ́lì àti àpèkọ | 6 |
| | • Iṣẹ́ ònkọ̀wé alátinúdá | 7 |
| | • Kíka oríṣiríṣi àmì àti pátákó ajúwe (ìtẹ̀síwájú ìtumọ̀ àmì ohùn àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe) | 7 |
| Ẹ̀kọ́ nípa àwọn ìró èdè Yorùbá | • Ẹ̀kọ́ nípa ìpàrójẹ àti ìsúnkì | 8 |
| Ọ̀rọ̀- èdè, ìdánmọ́rán àti àkàyé | • Àmì ohun (ìró èdè) | 9 |
| | • Ìtẹ̀síwájú lórí àkàyé àti àwọn ìbéèrè tí ó tẹ̀ lé e (yíyan àyọkà fún kíkà lórí kókó bí i: okòwò àṣejèrè abbl) | 9 |
| | • Ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ (ìtẹ̀síwájú lórí ìtumọ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀) | 10 |
| | • Ìtẹ̀síwájú lórí ìtumọ̀ ìsọnísọkí | 10 |

| | | | |
|---|---|---|---|
| Ọ̀rọ̀- èdè, ìdánmọ̀rán àti àkàyé | | • Èdè àmúlò | 11 |
| | | • Òǹkà (1000 -1,500) | 11 |
| | | • Òǹkà Yorùbá | 12 |
| | | • Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ | 12 |
| **STAGE 2** | | | |
| Kókò ọ̀rọ̀: ìdánmọ̀rán, ọ̀rọ̀ èdè àti àkàyé | | • Àkàyé: àṣìlò oògùn | 13 |
| | | • Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ Yorùbá | 13 |
| | | • Oṣù tó wà nínú ọdún | 14 |
| | | • Èdè àmúlò: ìgbà nínú ọdún | 14 |
| Èdè - ọ̀rọ̀ láméyítọ̀ lórí lítíréṣọ̀ | | • Àkànlò èdè | 15 |
| | | • Oríṣiríṣi òwe Yorùbá | 15 |
| | | • Ààtò ewì | 15 |
| | | • Ṣíṣe eré níṣe/onítàn | 16 |
| Ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere (kíka ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere) | | • Ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere | 17 |
| Ìṣọwọ́kọ̀wé | | • Ìtẹ̀síwájú lórí ìfàmìsí 11<br>• Ìdánwò lórí sípẹ́lì<br>• Iṣẹ́ òǹkọ̀wé alátinúdá | 18 |
| Ẹ̀kọ́ nípa ìṣọwọ́kọ̀wé (ìtẹ̀síwájú kíka oríṣiríṣi àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ) | | • Kíka oríṣiríṣi àmì àti pátákó ajúwe | 19 |
| Ẹ̀kọ́ nípa àwọn ìró èdè Yorùbá | | • Ẹ̀kọ́ nípa ìpàrójẹ àti ìsúnkì | 20 |
| Ọ̀rọ̀-èdè, ìdánmọ̀rán àti àkà ye | ẹ̀kọ́ nípa ìró èdè Yorùbá | • Ìró Yorùbá tí ó ń gba àmì ohùn | 21 |
| | yíyan àyọkà fún kíkà lórí kókó bí ìtọ́jú ara ẹni: àǹfààní lílo oògun, ewu tí ó wà nínu àṣìlò oògùn) | • Ìtẹ̀síwájú lórí àkàyé àti àwọn ìbéèrè tí ó tẹ̀lé e | |
| | ọgbọ́n àgbékalẹ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ | • Ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ | 22 |
| | àpẹẹrẹ àyọkà ṣókí | • Àpẹẹrẹ àwọn àyọkà ṣókí | 22 |
| | oríṣiríṣi èdè àmúlò oníṣẹ́ ìjọba: èdè oníṣègùn/dọ́kítà,èdè onímọ̀ ẹ̀rọ, èdè adájọ́, èdè kóòtù, èdè olùkọ́ abbl) | • Èdè àmúlò | 22 |
| | | • Òǹkà Yorùbá (1500 -2000) | 23 |

| | | |
|---|---|---|
| Ọ̀rọ̀- èdè, ìdánmọ̀ràn àti àkàyè (sísọ) | • Orúkọ Yorùbá<br>• Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ (ìtẹ̀síwájú) | 24 |
| **STAGE 3** | | |
| Ọ̀rọ̀- èdè, ìdánmọ̀ràn àti àkàye | • Àkàyé: ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ọmọ yorùbá<br>• Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ èdè yorùbá: ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ | 25 |
| | • Ìtẹ̀síwájú lórí ọjọ́ nínú ọ̀sẹ̀ àti oṣù nínú ọdún | 26 |
| | • Èdè àmúlò: iṣẹ́ àmúṣe | 27 |
| Èdè - ọ̀rọ̀ láméyítọ́ lórí lítíréṣọ̀ | • Àkànlò èdè | 28 |
| | • Ìlò òwe | 28 |
| | • Ọ̀nà èdè àti ìṣọwọ́ lo èdè nínú ewì | 29 |
| | • Ìjíròrò lórí ẹ̀kọ́ tí a rí kọ́ nínú ìtàn | 29 |
| Ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere (ìjíròrò lórí ẹ̀kọ́ tí a rí kọ́ nínú ìwé àròsọ ọlọ́rọ̀ geere) | • Ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere | 30 |
| Èrò nípa ìṣọwọ́kọ̀wé<br>Ẹ̀kọ́ nípa ìṣọwọ́kọ̀wé | • Ìdánrawò lórí àpèkọ àwọn ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí a yàn (tẹ̀síwájú)<br>• Iṣẹ́ òǹkọ̀wé aláìtinúdá<br>• Kíka oríṣiríṣi àmì àti pátákó ajúwe | 31 |
| Ẹ̀kọ́ nípa àwọn ìró èdè Yorùbá | • Ẹ̀kọ́ nípa ìpàrójẹ àti ìsúnkì | 32 |
| Ọ̀rọ̀- èdè, ìdánmọ̀ràn àti àkàyé | • Àmì ohùn lórí ọ̀rọ̀ oníṣílébù kan àti ọlọ́pọ̀ sílébù<br>• Ìtẹ̀síwájú lórí àkàyé àti àwon ìbéèrè tí ó tẹ̀lé e | 33 |
| | • Ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀<br>• Sísọ àyọkà ní sókí | 34 |
| | • Èdè àmúlò | 35 |
| Ọ̀rọ̀- ède, ìdánmọ̀ràn àti akàyé (sísọ) | • Òǹkà yorùbá<br>• Òǹkà yorùbá<br>• Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ (ìtẹ̀síwájú) | 36 |
| List of Participants | | 37 |

**KOKO ỌRỌ: ÌDÁNMỌRÁN, ỌRỌ ÈDÈ ÀTI ÀKÀYÉ** **IPELE KẸTA** **APÁ KÌN ÍN NÍ**

| ORÍ ỌRỌ | ÈRÒǸGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌNI | ÌTỌNISỌNÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌN |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Àsọtẹ́lẹ̀ ìtàn ọlọ́rọ̀ geere tàbí eré oníṣe tí wọ́n wò** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè sọ:<br><br>1. Ìtàn tó jẹ mọ́ ìrírí ọdẹ nínú igbó/ ìtàn oríṣiríṣi<br>2. Àsọtẹ́lẹ̀ àyọrísí ìtàn náà<br>3. ẹ̀kọ́ tí ó rí kọ́ nínú ìtàn náà | àwọn ìtàn lóríṣiríṣi tó dá lórí ìrírí ọdẹ tàbí jagunjagun nínú igbó | 1. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti sọ ìtàn lóríṣiríṣi<br>2. sọ àsọtẹ́lẹ àtubọ̀tàn ìtàn náà<br>3. pe akẹ́kọ̀ọ́ láti sọ ẹ̀kọ́ tí ìtàn náà kọ́ wọn | 1. sọ ìtàn lóríṣiríṣi<br>2. sọ àsọtẹ́lẹ̀ àtubọ̀tàn àwọn ìtàn náà<br>3. sọ ẹ̀kọ́ tí ìtàn náà kọ́ wọn | Oríṣiríṣi àwòrán tó bá àwọn ìtàn náà mu | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>1. sọ ìrírí tó ti rí/ gbọ́ rí<br>2. sọ èrò wọn lórí àtubọ̀tán ìṣẹ̀lẹ̀ ìtàn tàbi eré náà |
| **ọjọ́ tó wà nínú èdè Yorùbá** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. fi èdè Yorùbá ka àwọn ọjọ́ tó wà nínú ọ̀sẹ̀<br>2. ṣe ìdámọ̀ àwon ọjọ́ náà | 1. àwon ọjọ́ nínú ọ̀sẹ̀:<br>Sunday –àìkú<br><br>Monday –ajé<br><br>Tuesday– ìṣẹ́gun<br><br>Wednesday-ọjọ́ ru<br><br>Thursday - ọjọ́ bọ̀<br><br>Friday - ẹtì<br><br>Saturday–àbámẹ́ta<br><br>2. àlàyé nípa ọjọ́ kọ̀ọ̀kan<br>3. ìtàn nípa ọjọ́ kọ̀ọ̀kan orin tó rọ̀ mọ́ ọjọ́ kọ̀ọ̀kan | 1. kọ àwọn ọjọ́ wọ̀nyí sí ara pátákó ìkọ̀wé<br>2. sọ àwọn ọjọ́ wọ̀nyí ní èdè gẹ̀ẹ́sì àti ti Yorùbá<br>3. fi ọjọ́ wọ̀nyí kọ orin fùn akẹ́kọ̀ọ́<br>4. fún akẹ́kọ̀ọ́ ní àǹfààní láti pe àwọn ọjọ́ kọ̀ọ̀kan tí a kọ́ sí ara káàdì pélébé-pélébé | 1. pe àwọn ọjọ́ tí olùkọ] kọ sí ara pátákó tẹ̀ lé olùkọ́<br>2. dá àwọn ọjọ́ wọ̀nyí mọ̀ bí olùkọ́ ṣe kọ wọ́n sí inú káàdì pélebé pélébé<br>3. fi àwọn ọjọ́ wọ̀nyí kọrin aládùn | kàlẹ́ńdà<br><br>káàdì pélébé pélébé | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>1. dáhùn àwọn ìbéèrè nípà àwọn ọjọ́ tó wà nínú ọsẹ̀<br>2. fi ọjọ́ náà kọrin |

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Èdè àmúlò: ìkîni** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. sọ ìtumọ̀ èdè àmúlò b.a: èdè àmúlò jẹ́ èdè tî àwọn Yorùbá ń lò fún ìkîni, àkókò àti onîrúurú iṣẹ́<br>2. mọ bî ìkîni ṣe ṣe pàtàkì tó nînú àṣà Yorùbá<br>3. kî ni lórîṣirîṣi àkókò tó wà láàárîn ọjọ́ àti ìgbà | 1. ìkîni àti ìdáhùn láàárîn ọjọ́: àárọ̀,ọ̀sán àti alẹ́<br>- ẹ káàárọ̀<br>- ẹ káàsán<br>- ẹ káalẹ́<br>2. ìkîni àti ìdáhùn láàárîn àárọ̀, ọ̀sán àti alẹ́<br>3. pàtàkì ìkîni àti bî a ṣe ń kîni b.a:<br>- orî ìkúnlẹ̀ nî obînrin ń wà bî wọ́n bá ń kî àgbà<br>- Àwọn ọkùnrin á dọ̀bálẹ̀ gbalajà láti kî àgbà | 1. darî akẹ́kọ̀ọ́ láti fi bî a ṣe ń kin i ṣeré<br>2. Darî akẹ́kọ̀ọ́ láti kî ara wọn<br>3. fi àwòrán àwọn tó ń kîni han àwọn akẹ́kọ̀ọ́<br>4. Sọ ìdî pàtàkì tî Yorùbá fi ń kî ara wọn | 1. sọ ohun tî wọ́n mọ̀ nîpa àṣà ìkîni ṣáájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́<br>2. ṣe àpẹẹrẹ orîṣi ìkîni tî wọ́nti gbọ́rî ṣáájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́<br>3. fojú sî fîimù tàbî àwòrán tî olùkọ́ fi ń hàn wọ́n<br>4. mọ ìdî pàtàkì tî Yorùbá fi ń kî ara wọn lóòrè kóòrè | • àwòrán àwọn tó ń kîni<br>• akẹ́kọ̀ọ́<br>• fîimù tó ń ṣe àfihàn àṣà ìkîni | Kî olùkọ́:<br>ṣe ìbéèrè àti ìdáhùn lọ́wọ́ akẹ́kọ̀ọ́ lórî bî a ṣe ń kîni nî orîṣirîṣi ìgbà tî ó wà nînú ọjọ́ |

KỌ́KỌ́ Ọ̀RỌ̀ : ÈDÈ - Ọ̀RỌ̀ LÁMÈYÍTỌ̀ LÓRÍ LÍTÍRÉṢỌ̀ (KỌ́KỌ́ Ọ̀RỌ̀ KÉKÈKÉ) IPELE KẸTA APÁ KÌN ÍN NÍ

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| Àkànlò èdè | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè sọ ohun tí àkànlò èdè jẹ́ | 1. Ìtumọ̀ àkànlò èdè àpẹẹrẹ àkànlò èdè àti ìtumọ̀ rẹ̀<br>2. Lílo ohun tí a kọ sára káàdì ní gbólóhùn | 1. ṣàlàyé ohun tí àkànlò èdè jẹ́<br>2. sọ oríṣiríṣi àpẹẹrẹ àkànlò èdè | 1. Fara balẹ̀ láti gbọ́ àlàyé lórí ìtumọ̀ àkànlò èdè<br>2. Fara balẹ̀ láti gbọ́ oríṣiríṣi àkànlò èdè | • Àtẹ àkànlò èdè àti ìtumọ̀ rẹ̀<br>• Káàdì aláfihàn tí a kọ àkànlò èdè sí<br>• Pátákó ẹlẹ́mọ̀ọ́ | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>ṣe àtúntò àti ìtumọ̀ àkànlò èdè tí olùkọ́ dàrú bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ |
| òwe | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. sọ ohun tí òwe jẹ́ nínú èdè Yorùbá<br>2. sọ pàtàkì òwe nínú èdè Yorùbá<br>3. pa àwọn òwe kéékèèké | 1. ohun tí òwe jẹ́<br>2. pàtàkì òwe nínú èdè Yorùbá<br>3. Ìlo òwe ní èdè Yorùbá<br>4. ìtumọ̀ òwe tí a pa.b.a:<br>- Ilé ọba tó jó, ẹwà ló bù sí<br>- bá mi na ọmọ mi, kò dénú ọlọ́mọ | 1. sọ ohun tí òwe jẹ́<br>2. sọ pàtàkì òwe láàárín Yorùbá<br>3. sọ bí ọmọdé ṣe ń pa òwe níwájú àgbà "tótó bí òwe o" "ẹ̀yin àgbà ni ẹ má a ń sọ pé..." | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lóri ohun tí òwe jẹ́<br>2. tẹ́tí sí pàtàkì òwe láàárín Yorùbá<br>3. pa òwe tí wọ́n ti gbọ́ rí<br>4. sọ ìtumọ̀ òwe tí ó pa kí ó sì lò ó lọ́rọ̀<br>5. ṣe àkọsílẹ̀ àwọn òwe tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó ìkọ̀wé sínú ìwé wọn | • téèpù tí a ti gba òwe sí<br>• àwòrán oríṣiríṣi nípa òwe tí a pa | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. parí àwon òwe tí olùkọ́ sọ ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀<br>2. ṣe àlàyé àkókò tí a máa ń pa òwe méjì<br>3. so bí ọmọdé ṣe ń pa òwe níwájú àgba |
| Ewì ìwòyí àti ìdàgbàsókè àwùjọ | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. sọ ohun tí ewì ìwòyí jẹ́<br>2. sọ ìyàtọ̀ láàárín ewì ìwòyí àti àbáláyé<br>3. ka ewì tí olùkọ́ yàn fún wọn geere<br>4. ṣàlàyé ọ̀nà tí ewì ìwòyí gbá mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ | 1. ohun tí ewì jẹ́<br>2. oríṣi ewì<br>3. kíka ewì tí olùkọ́ yàn<br>4. ṣíṣe àlàyé àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ ìdàgbàsókè àwùjọ | 1. ṣàlàyé ohun tí ewì jẹ́<br>2. sọ oríṣi ewì tó wà<br>3. kíka ewì tí olùkọ́ kọ sí ara káàdìbọ́ọ̀dù<br>4. ri pé akẹ́kọ̀ọ́ ka ewì náà<br>5. ṣi ṣàlàyé àwọn kókó ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ ìdàgbàsókè | 1. tẹ́tí si] àlàyé olùkọ́ lórí ohun tí ewì jẹ́ àti oríṣi ewì<br>2. kópa nínú kíkà ewì nínú kíláàsì<br>3. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí àwọn kókó tó jẹ mọ́ ìdàgbàsókè àwùjọ | • káàdìbọ́ọ̀dù tí a kọ ewì tí a yàn sí<br>• àwòrán nípa ohun tí ewì ń sọ<br>• ìwé ìròyìn àtìgbàdégbà tó ṣe àfihàn kókó ọ̀rọ̀ tí ewì dá lé | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. ka ewì kan pàtó<br>2. kí ó sì: ṣàlàyé àwon ọ̀rọ̀ tó ta kókó<br>3. fa ẹ̀kọ́ tí ó jẹ mọ́ ìdagbàsók è àwùjọ ibẹ̀ yọ |

**KÓKÓ ỌRỌ : ÈDÈ - ỌRỌ LÁMÈYÍTỌ LÓRÍ LÍTÍRÉṢỌ (KÓKÒ ỌRỌ KÉKÈKÉ)** **IPELE KẸTA** **APÁ KÌN ÌN NÍ**

| ORÍ ỌRỌ | ÈRÒNGBÀ | | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌNI | ÌTỌNISỌNÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌN |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Kíka eré oníṣe** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. ka ìwé eré onítàn/oníṣe<br>2. tún ìtàn inú rẹ̀ sọ ní ṣókí<br>3. dárúkọ àwọn ẹ̀dá ìtàn inú eré náà<br>4. sọ irú ìwà tí ẹ̀dá ìtàn kọ̀ọ̀kan hù<br>5. sọ ẹ̀kọ́ tí eré onítàn náà kọ́ ní | 1. kí ni eré oníṣe?<br>2. kíka ìwé eré oníṣe/onítàn ní kíláàsì<br>3. àtúnsọ ìtàn eré náà ní ṣókí<br>4. ẹ̀dá ìtàn eré àti ìwà wọn<br>5. ẹ̀kọ́ inú eré onítàn/oníṣe náà | 1. ṣàlàyé ohun tí eré oníṣe/onítàn jẹ́<br>2. yan ìwé eré oníṣe/onítàn kan tí ó kún fun ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí<br>3. darí kíka ìwé eré oníṣe/onítàn náà ní kíláàsì<br>4. darí ìsọnísókí ìtàn inú eré náà ní kíláàsì<br>5. darí ìjíròrò lórí kókó ẹ̀kọ́ tí ó súyọ nínú eré náàdarí ìjíròrò lórí ẹ̀dá ìtàn àti ìwà wọn | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ohun tí eré oníṣe/onítàn jẹ́ ka ìwé eré oníṣe/onítàn tí olùkọ́ yàn<br>2. kópa nínú ìjíròrò nípa ẹ̀kọ́ tí ó súyọ nínú ìtàn eré náà<br>3. kópa nínú ìjíròrò lórí ẹ̀dá inú eré náà àti ìhùwàsí wọn | ohun èlò ìṣeré tó bá eré oníṣe/onítàn inú ìwé àṣàyàn mu | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. dárúkọ ẹ̀dá ìtàn pàtàkì jùlọ<br>2. kọ ìṣẹ̀lẹ̀ méjì pàtàkì inú ìtàn eré náà<br>3. sọ ẹ̀kọ́ tí ó rí kọ́ nínú eré oníṣe/onítàn tí ó kà |

**KÓKÒ ỌRỌ̀: ÌTÀN ỌLỌ́RỌ̀ GEERE** **IPELE KẸTA** **APÁ KÌN ÍN NÍ**

**KÓKÓ ỌRỌ̀ KÉKÈKÉ : OHUN TÍ ÌTÀN ỌLỌ́RỌ̀ GEERE JẸ́**

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒǸGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè sọ ohun tí ìtàn ọlọ́rọ̀ geere jẹ́ | 1. Ohun tí ìtàn ọlọ́rọ̀ geere jẹ́<br>2. Àpẹẹrẹ oríṣiríṣi ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere. b.a:<br>-D.O Fágúnwà: ògbójú ọdẹ nínú igbo irúmọlẹ̀<br>-Oládèjì Òkédìjí Atótó arére<br>-Kọ́lá Akínlàdé Owó ẹ̀jẹ̀ | 1. ṣàlàyé ohun tí ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere jẹ́<br>2. ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ ìwé ìtàn àròsọb ọlọ́rọ̀ geere<br>3. àwòrán àwọn òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere àti orúkọ ìwé wọn | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ nípa ohun tí ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere jẹ́<br>2. dárúkọ àpẹẹrẹ mẹ́ta lára àwn ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere tí olùkọ́ ṣe | àtẹ àwòrán àwon òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere àti ìwé wọn | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. ṣe àlàyé ohun tí ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere jẹ́<br>2. dárúkọ àwọn òǹkọ̀wé ìtàn àròsọ mẹ́ta àti ìwé wọn |

KỌ́KỌ̀ Ọ̀RỌ̀: ÈDÈ - ÌṢỌWỌ́KỌ̀WÉ (ÈRÒ NÍPA ÌṢỌWỌ́KỌ̀WÉ) IPELE KẸTA APÁ KÌN ÍN NÍ

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢẸ IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Ìtẹ̀síwájú lórí ìfàmìsí 1** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. Dá oríṣiríṣi àkọtọ́ (àmì) mọ̀<br>2. ṣe àmúlò rẹ̀ bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ | Oríṣiríṣi àkọtọ́ (àmì) b.a<br><br>- àmì kọ́lọ́ọ̀nù (:)<br>- àmì àdínadí kọ́lọ́ọ̀nù (;)<br>- ìdánudúró (.)<br>- ìdánudúró díẹ̀ (,) | 1. ṣàlàyé oríṣiríṣi àmì àti ìwulò wọn<br>2. kọ àmì sí ara pátákó<br>3. tọ́ akẹ́kọ̀ọ́ sọ́nà láti kọ àwọn àmì náà sára pátákó | 1. te]tí sí àlàyé olùkọ́<br>2. kópa nínú kíkọ sí ara pátákó<br>3. kọ àkọsílẹ̀ ara pátákó sínú ìwé rẹ̀ | Káàdì pélébé<br><br>tí a kọ àkọtọ́ sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>1. ṣe ìdámọ̀ àwọn àkọtọ (àmì) tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó<br>2. kọ àkọsílẹ̀ kí o sì ṣe àmúlò àwọn àmì wọ̀nyí |
| **Ìtẹ̀síwájú lórí sípélì àti àpèkọ** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. dá oríṣiríṣi àkọtọ́ (àmì) mọ̀<br>2. ṣe àmúlò rẹ̀ bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ<br>3. ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ nípa síso lẹ́tà álífábẹ́tì kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì papọ̀<br>4. sípẹ́lì ọ̀rọ̀ Yorùbá bí ó ti yẹ<br>5. kọ àpèkọ ọ̀rọ̀ Yorùbá ní àkọ́yanjú | 1. àyẹ̀wò oríṣiríṣi àkọtọ́ (àmì)<br>2. lo álífábẹ́tì Yorùbá láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀<br>3. sípẹ́lì àwon ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn èdè Yorùbá ní àkọpé àti àkọtọ́.<br>4. Àpèkọ ẹyọ ọ̀rọ̀ àti oríṣiríṣi gbólóhùn | 1. ṣe àyẹ̀wò oríṣiríṣi àkọtọ́ (àmì)<br>2. Fi káàdì aláfihàn tí a kọ sílébù kọ̀ọ̀kan sí han akẹ́kọ̀ọ́ láti pè<br>3. Darí akẹ́kọ̀ọ́ láti sípẹ́lì ọ̀rọ̀ Yorùbá ní sílébù, sílébù<br>4. Ka ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí a fẹ́ pè fún akẹ́kọ̀ọ́ sí ara pátákó fún akẹ́kọ̀ọ́ láti pè é tẹ̀ lé e<br>5. Pe àpèkọ tààrà fún akẹ́kọ̀ọ́<br>6. Àtúnkà ẹyọ ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí a pè fùn akẹ́kọ̀ọ́ | 1. Kópa nínú àtúnyẹ̀wò oríṣiríṣi àkọtọ́ (àmì)<br>2. Pe àwọn ọ̀rọ̀ tí a kọ sí ara káàdì aláfihàn síta<br>3. Sípẹ́lì ọ̀rọ̀ Yorùbá ní sílébù, sílébù<br>4. Pe ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó tẹ̀ lé olùkọ́<br>5. Kópa nínú àpèkọ tí olùkọ́ pè fún wọn | Káàdì aláfihàn tí a kọ sílébù ẹyọ ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn abọ́dé sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>ṣe àtúnṣe ọ̀rọ̀ àpèkọ tí ó ṣì |

KỌ́KỌ́ Ọ̀RỌ̀: ÈDÈ - ÌṢỌWỌ́KỌ̀WÉ (ÈRÒ NÍPA ÌṢỌWỌ́KỌ̀WÉ) IPELE KẸTA APÁ KÌN ÍN NÍ

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÒǸGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Iṣẹ́ òǹkọ̀wé alátinúdá** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. sọ ohun tí àròkọ jẹ́<br>2. dá oríṣiríṣi àròkọ mọ̀<br>3. lo èdè Yorùbá tó dán mọ́rán láti fi gbé èrò àtinúdá rẹ̀ kalẹ̀ lórí kókó ọ̀rọ̀ kan tí a bá gbé síwájú rẹ̀ | 1. ohun tí àròkọ jẹ́<br>2. kíkọ oríṣiríṣi àròkọ<br>àpẹẹrẹ<br>àròkọ aṣàpèjúwe<br>aláríìíyànjiyàn<br>aláàlàyé abbl | 1. ṣe àlàyé lórí ohun tí àròkọ jẹ́<br>2. ṣe àlàyé lórí oríṣiríṣi àròkọ<br>3. sàlàyé lórí àwọn èdè Yorùbá tí a fi ń gbé èrò àtinúdá kalẹ̀ lórí kókó ọ̀rọ̀ kan | Tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí:<br>i. ohun tí àròkọ jẹ́<br>ii. oríṣiríṣi àròkọ<br>iii. lo èdè Yorùbá tó dán mọ́rán láti fi gbé èrò àtinúdá rẹ̀ kalẹ̀ | Àwọn ohun èlò tó bá orí ọ̀rọ̀ àròkọ mu | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. kọ ohun tí àròkọ jẹ́<br>2. sọ oríṣiríṣi àròkọ tí ó wà<br>3. lo èdè Yorùbá tí ó bá dán mọ́rán fi gbé èrò àtinúdá rẹ̀ kalẹ̀ |
| **Kíka oríṣiríṣi àmì àti pátákó ajúwe** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. dá àwọn àmì àti àwọn ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ojú pópó mọ̀<br>2. sọ ìtumọ̀ àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe pópó | 1. ṣíṣe ìdámọ̀ àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ojú pópó<br>2. sísọ ìtumọ̀ àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ojú pópó<br>bí àpẹẹrẹ<br>-iná ìdarí ọkọ̀<br>-àmì ara pátákó ajúwe oníkìlọ̀<br>-onítọ́nisọ́nà oníròfindè | 1. ṣàfihàn oríṣiríṣi àwòrán àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ojú pópó<br>2. sọ orúkọ oríṣiríṣi àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ojú pópó<br>3. ṣe àlàyé ìtumọ̀ àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ojú pópó | 1. wo oríṣiríṣi àwòrán àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ojú pópó<br>2. tẹ́tí sí orúkọ oríṣiríṣi àwòràn àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ojú pópó<br>3. tẹ́tí sí àlàyé ìtumọ̀ àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ojú pópó | Àtẹ àwòrán àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe ojú pópó | 1. kí ni àmì pupa dúró fún nínú ìdarí ọkọ̀?<br>2. kí niàwọ àmì tí ó ń ṣàfihàn kí ọkọ̀ tẹ̀ síwájú?<br>3. Tọ́ka sí àwòràn àmì kọ̀ọ̀kan ti<br>- Oníkìlọ̀<br>- Onítọ́nisọ́nà<br>- Oníròfindè |

KÓKÒ ỌRỌ: ẸKỌ NÍPA ÀWỌN ÌRÓ ÈDÈYORÙBÁ IPELE KẸTA APÁ KÌN ÍN NÍ

| ORÍ ỌRỌ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌNI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **ẹ̀kọ́ nípa ìpàróję àti ìsúnkì** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. ṣe àlàyé nǹkan tí ìpàróję àti ìsúnkì jẹ́<br>2. ṣe ìsúnkì ọ̀rọ̀ méjì nípa ìgbésẹ̀ ìpàróję | 1. ìpàróję ìbẹ̀rẹ̀ kọ́nsónántì. b.a<br>-Adémọ́lá di Démọ́lá<br>-ìkòkò di kòkò<br>-iyàrá di yàrá<br>2. ìpàróję láàárín ọ̀rọ̀ méjì<br>-aya + ọba di ayaba<br>-ojú + ilé di ojulé<br>-ewé + oko di ewéko<br>-ta + ọjà di tajà<br>abbl | Kọ àpẹẹrẹ sí ojú pátákó, yóò sì ṣe àlàyé ìpàróję | 1. tẹ́tí sí àlàyé lórí ìpàróję àti ìsúnkì<br>2. sọ àpẹẹrẹ tirẹ̀ | Kádíbọ́ọ̀dù tí a kọ àpẹẹrẹ sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́ kọ:<br>1. ẹyọ ọ̀rọ̀ méta tí a ti pa ìró jẹ nìkan<br>2. ọ̀raọ̀ méta tí a ti pa ìró jẹ tí a sì ṣe ìsúnkì |

**KỌ́KỌ́ ỌRỌ̀: ỌRỌ̀- ÈDÈ, ÌDÁNMỌ̀RÁN ÀTI ÀKÀYÉ** **IPELE KẸTA** **APÁ KÌN ÌN NÍ**

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌNI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Àmì ohun (ìró èdè)** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. ṣe àlàyé lórí oríṣi ohùn Yorùbá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta àti àmì wọn. b.a<br>ohùn òkè /<br>ohùn àárín (kò ní àmì)<br>ohùn ìsàlẹ̀ \<br>2. lò wọ́n bí ó ti tọ́ lórí ọ̀rọ̀ Yorùbá | Àlàyé lórí oríṣi ohùn Yorùbá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta àti àmì wọn:<br>Ohùn òkè /<br>Ohùn àárín (kò ní àmì)<br>Ohun ìsàlẹ̀ \ | ṣe àlàyé lórí oríṣiríṣi ìró èdè (ohùn Yorùbá) mẹ́tẹ̀ẹ̀ta | Tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí oríṣiríṣi ìró èdè (ohùn Yorùbá) mẹ́tẹ̀ẹ̀ta | Káḍíbọ́ọ̀dù tí ó ń ṣe àfihàn àwọn àmì ohùn Yoruba mẹ́tẹ̀ẹ̀ta si | Kí akẹ́kọ̀ọ́ kọ àwọn ìró èdè (àmì ohùn) Yorùbá tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó sínú ìwé wọn |
| **Ìtẹ̀síwájú lórí àkàyé àti àwọn ìbéèrè tí ó tẹ̀ lé e** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. Ka ìwé àṣàyàn ní àkàyé<br>2. Dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó súyọ nínú àkàyé náà | 1. Kíka àyọkà tí a yàn ní àkàyé<br>2. Ìbéèrè àti ìdáhùn lórí àkàyé tí a yàn.<br>B.a:<br>-okòwò àṣejèrè<br>-iṣẹ́ lòògùn ìṣẹ́<br>-oríṣiríṣi iṣẹ́ àgbẹ̀<br>-aṣerinlóge<br>-mẹkáníìkì<br>-dọ́kítà abbl | 1. yan àyọkà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́<br>2. Darí kíka àyọkà<br>3. darí ḍídáhùn àwọn ìbéèrè tí ó súyọ nínú àyọkà<br>4. ṣe àlàyé àwọn ọ̀rọ̀ èdè àmúlò àti ọ̀rọ̀ mìíràn tí ó ta kókó tí ó súyọ nínú àyọkà | 1. ka àṣàyàn àyọkà ní àkàyé<br>2. dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó sútọ nínú àyọkà<br>2. Tẹ́tí sí àlàyé tí olùkọ́ ṣe lórí àwọn ọ̀rọ̀ èdè àmúlò àti ọ̀rọ̀ mìíràn tí ó ta kókó tí ó súyọ nínú àyọkà | • Ìwé àyọkà<br>• Àwòrán àwọn ohun tí ó jẹ mọ́ àyọkà | 1. Ka àyọkà lórí iṣẹ́ alágbàfọ̀<br>2. Dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó súyọ nínú àyọkà lórí iṣẹ́ alágbàfọ̀ |

KOKO ỌRỌ: ỌRỌ- ÈDÈ, ÌDÁNMỌRÁN ÀTI ÀKÀYÉ IPELE KẸTA APÁ KÌN ÍN NÍ

| ORÍ ỌRỌ | ÈRONGBA | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌNI | ÌTỌNISỌNÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌN |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>Sọ ohun tí ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ jẹ́ | ṣíṣàlàyé ìtúmọ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ | 1. ṣàlàyé ìtumọ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀. b.a<br>dídà ọ̀rọ̀ tí ẹnìkan tí sọ, sọ lọ́nà mìíràn láìyí ìtumọ̀ padà<br>2. sọ àpẹẹrẹ ṣíṣe ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ b.a<br>**GBÓLÓHÙN**<br>ọmọ náà jẹ ẹ̀bà ikùn rẹ̀ wú bàǹtù<br>**ẸDÀ ÒYE ỌRỌ**<br>Ouńjẹ tí ọmọ náà jẹ mú kí ikùn rẹ̀ tóbi gelete | 1. tẹ́tí sí àlàyé ìtumọ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ tí olùkọ́ ṣe<br>2. tẹ́tí sí àlàyé àpẹẹrẹ tí olùkọ́ ṣe | káḍíbọ́ọ̀dù tí a kọ ìtumọ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ sí àti èyí tí a kọ àpẹẹrẹ sí | 1. kí akẹ́kọ̀ọ́ sọ ìtumọ̀ òye ọ̀rọ̀<br>2. gbìyànjú láti ṣe ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ tí olùkọ́ fún un |
| **Ìtẹ̀síwájú lórí ìtumọ̀ ìsọníṣókí** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. sọ ìtumọ̀ ìsọníṣókí<br>2. sọ ìtàn inú àyọkà ní ṣókí | 1. ìtumọ̀ ṣókí/ ìsọníṣókí<br>2. kíka ìwé àṣàyàn/àyọkà geere<br>3. ìtàn inú àyọkà ní ṣókí | 1. ìtumọ̀ ohun tí a ń pè ní "ṣókí "<br>2. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti yan àyọkà fún kíkà<br>3. ìtàn inú àyọkà ní ṣókí<br>4. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti ka ìwé àṣàyàn/àyọkà geere<br>5. tọ́ akẹ́kọ̀ọ́ sọ́nà lórí bí a ṣe ń ṣe ìsọníṣókí. b.a<br>kíkọ lédè ara ẹni kókó tí ó ṣe pàtàkì nìkan ni ó pọ̀n dandan, èrò inú àyọkà tí a ń sọ ní ṣókí nìkan láìṣe àfikún tàbí àyọkúrò | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ohun tí à ń pè ní "ṣókí"<br>2. yàn/ka àyọkà , sì tẹ̀ lé ìtọ́ni olùkọ́ fún ìsọníṣókí<br>3. sọ ìtàn inú àyọkà náà ní ṣókí | • àwòrán tí ó bá èrò inú àyọkà mu<br>• káàdí aláfihàn tí a kọ àwon ọ̀rọ̀ tuntun sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. sọ ìtumọ̀ "ìsọníṣókí"<br>2. sọ ìtàn tí olùkọ́ sọ fún un ní ṣókí |

**KÓKÓ ỌRỌ: ỌRỌ- ÈDÈ, ÌDÁNMỌRÁN ÀTI ÀKÀYÉ** **IPELE KẸTA** **APÁ KÌN ÍN NÍ**

| **ORÍ ỌRỌ** | **ÈRÒŃGBÀ** | **ÀKÓÓNÚ IṢẸ́** | **ÀMÚṢE IṢẸ́** | | **OHUN ÈLÒ ÌKỌNI** | **ÌTỌNISỌNÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌN** |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Èdè àmúlò** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>ṣe àlàyé ohun tí èdè àmúlò jẹ́ | ṣíṣàlàyé ohun tí èdè àmúlò jẹ́. b.a ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ti ẹgbẹ́/ ọ̀wọ́ tí wọ́n jọ màjọṣepọ̀ nípa iṣẹ́ òṣèlú, ọrọ̀ ajé, ẹ̀sìn, abbl, má a ń lò fún ìbára ẹni sọ̀rọ̀ – gbóra ẹniyé | 1. ṣàlàyé ohun tí èdè àmúlò jẹ́<br>2. sọ orísirísi ẹgbẹ́/ ọ̀wọ́ tí wọ́n ní èdè àmúlò<br>3. ṣàmúlò àwòrán tí ó se àfihàn orísirísi òṣìṣẹ́, ẹlẹ́sìn,olóṣèlú,oníṣòwò abbl | 1. tẹ]tí sí àlàyé nípa ìtumọ̀ èdè àmúlò<br>2. tẹ̀tí sí orísirísi ẹgbẹ́/ ọ̀wọ́ tí wọ́n ní èdè àmúlò | Àwòrán àti fídíò | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. sọ ìtumọ̀ èdè àmúlò<br>2. dárúkọ ẹgbẹ́/ọ̀wọ́ mẹ́ta tí wọ́n ní èdè àmúlò |
| **Òǹkà**<br><br>**(1000 - 1,500)** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. ka àwọn òǹkà Yorùbá láti ẹgbẹ̀rún dé ẹgbẹ̀rún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta.<br>2. dá àwọn òǹkà wònyí mọ̀ lọ́kọ̀ọ̀kan<br>3. ṣe àròpọ̀ àti àyọkúrò pẹ̀lú àwọn òǹkà náà | 1. òǹkà Yorùbá láti ẹgbẹ̀rún dé ẹgbẹ̀rún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta<br>2. àlàyé kíkún nípa òǹkà àpẹẹrẹ:<br>a. 1100- ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀fà= Igba mẹ́fà dín ọgọ́rùn ún<br>b. 1200 – ẹgbẹ̀fa =igba mẹ́fà (200X6)<br>1400 egbèje= igba méje (200X7)<br>d.1500 -ẹgbẹ̀rún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta (1000+500) | 1. Tọ akẹ́kọ̀ọ́ sọ́nà láti ka òǹkà láti ẹgbẹ̀rún dé ẹgbẹ̀rún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta<br>2. ṣe àlàyé ìgbésẹ̀ òǹkà ní kíkún | 1. ka òǹkà láti ẹgbẹ̀rún dé ẹgbẹ̀rún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta<br>2. da òǹkà tí a kọ sára pátákó mọ̀ ní ọ̀kọ̀ọ̀kan<br>3. kọ òǹkà tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó sínú ìwé | • káàdíbọ́ọ̀dù tí a kọ òǹkà láti ẹgbẹ̀rún dé ẹgbẹ̀rún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta<br>• káàdì pélébé tí a kọ òǹkà kọ̀ọ̀kan sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. ka òǹkà láti ẹgbẹ̀rún dé ẹgbẹ̀rún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta<br>2. ka àwọn òǹkà tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó |

KÓKÒ ỌRỌ̀: ỌRỌ̀- ÈDÈ, ÌDÁNMỌ̀RÁN ÀTI ÀKÀYÉ IPELE KẸTA APÁ KÌN ÍN NÍ

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| Orúkọ Yorùbá | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. sọ pàtàkì orúkọ nílẹ̀ Yorùbá<br>2. sọ oríṣiríṣi ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ irú orúkọ bẹ́ẹ̀ | 1. pàtàkì orúkọ nílẹ̀ Yorùbá<br>2. oríṣiríṣi ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ irú orúkọ bẹ́ẹ̀ | Sọ pàtàkì orúkọ láàárín àwọn Yorùbá àti ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ bẹ́ẹ̀ (orúkọ ni ìroni, oríkì a sì má a ro ènìyàn) | 1. sọ oríṣiríṣi orúkọ Yorùbá tí wọ́n bá mọ̀<br>2. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí àwọn orúkọ Yorùbá | • pátákó ẹlẹ́mọ̀ọ́<br>• káàdì pélébé-pélébé tí a kọ àwọn orúkọ Yorùbá sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>1. sọ ìdí tí àwọn Yorùbá fi ń jẹ́ orúkọ tí wọ́n ń jẹ́<br>2. ṣe ìwádìí àwọn orúkọ Yorùbá mìíràn bọ̀ láti ilé |
| Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>ṣe àlàyé kíkún àti àpẹẹrẹ lórí<br><br>1. ọ̀rọ̀ orúkọ<br>2. ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ<br>3. ọ̀rọ̀ àpèjúwe | Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀<br><br>1. ọ̀rọ̀ orúkọ<br>2. ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ<br>3. ọ̀rọ̀ àpèjúwe | ṣe ìtumọ̀ àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀. Kọ àpẹẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀ tí ó lè wà lábẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kán àpẹẹrẹ<br>**1. <u>ọ̀rọ̀ orúko</u>**<br>- ilé, igi, ojú, Ayọ̀, Bọ́lá, Tolú<br>**2. <u>ọ̀rọ̀ arọ́pò orúko</u>**<br>- mo, o, a, ẹ,<br>**3. <u>ọ̀rọ̀ àpèjúwe</u>**<br>- dúdú, funfun, pupa | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan<br>2. kọ àwọn àpẹẹrẹ tí olùkọ́ kọ sókè<br>3. pe àwọn ọ̀rọ̀ náà bí olùkọ́ ṣe pè é fún wọn | Káàdíbọ́ọ̀dù àti<br><br>Káàdì pélébé-pélébé | Kí akẹ́kọ̀ọ́ tọ́ka sí irúfẹ́ ọ̀rọ̀ tí ó wà lábẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan nínú gbólóhùn kéékèèkéé tí olùkọ́ kọ sójú pátákó |

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Àkàyé: àṣìlò oògùn** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. sọ àwọn ìgbésẹ̀ fún àkàyé b.a<br>- gbọ́dọ̀ ka àyàkà ní àkàyé kí a lè ní oye ohun tí ó dá lé<br>- kí a ka àwọn ìbéèrè tó jẹyọ lábẹ́ àyọkà dáadáa kí ó lè mọ ibi tí ìdáhùn gbé súyọ<br>2. sọ ìtàn tàbí ohun tí ó kà ní ṣókí<br>3. sọ àwọn ọ̀nà díẹ̀ tí a fi lè dẹ́kun àṣìlò oògun | 1. kíka ìwé àṣàyàn b.a kíka àyọkà lórí ìlera<br>2. ìsọníṣókí ìtàn tàbí ohun tí a kà<br>3. ohun tí àṣìlò oògùn jẹ́<br>4. àǹfààní tó wà nínú oògùn lílò<br>5. ewu tó wà nínú àṣìlò oògùn | 1. ṣàlàyé ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ tó ta kókó tàbí tí ó jẹ́ tuntun<br>2. sọ ní sókí ohun tí ó kà nínu àyọkà nípa ìlera<br>3. sọ àǹfààní oògun lílò<br>4. ṣàlàyé ewu tó wà ninu àṣìlò oògùn<br>5. ṣàláyé díẹ̀ lára ọ̀nà tí a fi le dẹ́kun àṣìlò oògùn láwùjọ wa<br>6. jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ dáhùn ìbéèrè inú àyọkà | 1. ka àyọkà náà ní àkàsínú kí o sì ṣe àkíyèsí àwọn ọ̀rọ̀ tó ta kókó<br>2. tẹ́tí sí olùkọ́ nípa ìlera: àǹfààní oògùn lílò àti ewu tó wà nínú àṣìlò oògùn<br>3. tẹ́tí sí àlàyé nípa ọ̀nà tí a lè fi dẹ́kun àṣìlò oògùn<br>4. dáhùn ìbéère tí ó tẹ̀lé àyọkà sí inú ìwé rẹ̀ | - káḿbọ́ọ̀dù<br>- àwòrán<br>- fídíò<br>- fíìmu<br>- akẹ́kọ̀ọ ga an | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. kọ kókó ọ̀rọ̀ inú àyọkà<br>2. sọ ọ[nà méjì tí a fi lè ṣi oògùn lò<br>3. sọ àǹfààní oògùn lílò<br>4. sọ ewu mẹ́ta tí ó wà nínú ṣíṣi oògùn lò<br>5. sọ ọ̀nà méjì tí a fi lè dẹ́kun àṣìlò oògùn |
| **Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ Yorùbá** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. dárúkọ àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ Yorùbá<br>2. tọ́ka si ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan nínú gbólóhùn<br>3. sọ iṣẹ́ tí ọ̀kọ̀ọ̀kan ń ṣe nínú gbólóhùn | A. Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ Yorùbá:<br>1. ọ̀rọ̀ orúkọ<br>2. ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ<br>3. ọ̀rọ̀ ìṣe<br>4. ọ̀rọ̀ àpèjúwe<br>5. ọ̀rọ̀ atọ́kùn<br>6. ọ̀rọ̀ asopọ̀<br>B. àlàyé kíkún lórí ipò àti iṣẹ́ wọn nínú gbólóhùn | 1. to ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ Yorùbá ní Sísẹ̀ n tẹ̀lé<br>2. sọ àpẹẹrẹ ìkọ̀ọ̀kan fún akẹ́kọ̀ọ́<br>3. ṣe àlàyé kíkún lórí ipò àti iṣẹ́ ìkọ̀ọ̀kan nínú gbólóhùn<br>4. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti sọ àpẹẹrẹ tiwọn<br>5. jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ṣe àkọsílẹ̀ ohun tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó ìkọ̀wé | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan<br>2. ṣe àpẹẹrẹ tirẹ̀ pẹ̀lú ìtọ́ni olùkọ́<br>3. ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ohun tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó ìkọ̀wé | • káḿbọ́ọ̀dù tí a kọ ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ Yorùbá sí<br>• káàdì pélébe-pélébé<br>• àpótí ẹlẹ́mọ̀ọ́ | 1. Kí akẹ́kọ̀ọ́ sọ àpẹẹrẹ ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ Yorùbá mẹ́ta<br>2. Lo ìkọ̀ọ̀kan ní gbólóhùn ní èdè Yorùbá |

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| Oṣù tó wà nínú ọdún | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. fi èdè Yorùbá ka àwọn oṣù tó wà nínú ọdun<br>2. yóò le dá àwọn oṣù náà mọ̀ | 1. àwọn oṣù nínú ọdún:<br>oṣù kìíní - ṣẹrẹ<br>oṣù kejì - èrèlé<br>oṣù kẹta - ẹrẹ́nà<br>oṣu kẹrin - igbe<br>oṣù karùn ún- èbìbì<br>oṣù kẹfà - òkudù<br>oṣù keje - agẹmọ<br>oṣù kẹjọ - ògún<br>oṣù kẹsàn án- ọ̀wẹwẹ̀<br>oṣù kẹwàá - ọ̀wàrà<br>oṣù kọkànlá - belu<br>oṣù kejìlá - ọ̀pẹ | 1. kọ àwọn oṣù wọ̀nyí sí ara pátákó ìkọ̀wé<br>2. sọ àwọn oṣù wọ̀nyí ní èdè Yorùba àti ní èdè gẹ̀ẹ́sì<br>3. kọ àwọn oṣù wọ̀nyí ní orin aládùn fún akẹ́kọ̀ọ́<br>4. pe akẹ́kọ̀ọ́ ní ọ̀kọ̀ọ̀kan láti sọ àwọn oṣù wọ̀nyí kí wọ́n sì kọ wọ́n sí inú ìwé wọn | 1. pe àwọn oṣù tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó tẹ̀lé bí ó ṣe ń pè wọ́n<br>2. dá àwọn oṣù wọ̀nyí mọ̀ bí olùkọ́ ṣe kọ wọ́n sínú káàdì pélébé-pélébé<br>3. fi àwọn oṣù wọ̀nyí kọrin bí olùkọ́ ṣe kọ wọ́n | • káàdì pélébé pélébé tí a kọ oṣù tó wà nínú ọdún sí<br>• kàlẹ́ńdà tó ń ṣe àfihàn oṣù nínú ọdún | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>1. dáhùn ìbéèrè nípa àwọn oṣù nínú ọdún<br>2. fi àwọn oṣù náà kọ orin |
| Èdè àmúlò: ìgbà nínú ọdún | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. dárúkọ i[gbà tí ó wà nínú ọdún<br>2. sọ ohun pàtàkì tí ó máa ń wáyé tí a lè fi dá ìgbà kọ̀ọ̀kan mọ̀ | 1. ìgbà tí ó ṣe pàtàkì láàárín ọdún<br>- ìgbà ẹ̀rùn<br>- ìgbà òjò<br>- ìgbà ọyẹ́<br>- ìyàn<br>2. ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní ìgbà kọ̀ọ̀kan b.a<br>- ìgbà ayọ̀/yíyọ nínú ewu<br>- ìgbà ọyẹ́ | 1. ṣàlàyé lórí oríṣiríṣi ìgbà tí ó wà nínú ọdún àti nǹkan pàtàkì tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní ìgbà kọ̀ọ̀kan<br>2. sọ ìtàn tí ó bá ìgbà kọ̀ọ̀kan mu<br>3. kọ orin tí ó bá ìgbà kọ̀ọ̀kan mu<br>4. ka ewì kékeré tí ó bá ìgbà kọ̀ọ̀kan mu | 1. tẹ́tí sí àlàyé tí olùkọ́ ń ṣe<br>2. kópa nínú orin tí ó jẹ mọ́ ìgbà. b.a<br>- òjò rọ̀ kílẹ̀ tutù …<br>- òjò ń rọ̀ ṣeré nínú ilé….<br>3. sọ àwọn oríṣiríṣi ìgbà tí ó wà nínú ọdún àti ohun tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ nínú wọn | • àwòrán oríṣiríṣi tí ó bá ìgbà kọ̀ọ̀kan mu<br>• ohun èlò ti ó bá ìgbà kọ̀ọ̀kan mu b.a aṣọ súẹ́tà abbl | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. dárúkọ ìgbà tí ó wà nínú ọdún<br>2. sọ ìmúra tí ó bá ìgbà kọ̀ọ̀ kan mu<br>3. kọ orin tàbí ka ewì nípa ìgbà |

**KÓKÓ ỌRỌ : ÈDÈ -ỌRỌ LÁMÈYÍTỌ LÓRÍ LÍTÍRÉṢỌ** **IPELE KẸTA** **APÁ KEJÌ**

| **ORÍ ỌRỌ** | **ÈRÒNGBÀ** | **ÀKÓÓNÚ IṢẸ́** | **ÀMÚṢE IṢẸ́** | | **OHUN ÈLÒ ÌKỌNI** | **ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N** |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | **OLÙKỌ́** | **AKẸ́KỌ̀Ọ́** | | |
| **Àkànlò èdè** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè tọ́ka sí àkànlò èdè nínú gbólóhùn | 1. Ìdámọ̀ àkànlò èdè<br>2. Lílo káàdì tí a kọ àkànlò èdè sí<br>3. Lílo àtẹ àkànlò èdè | 1. Tọ́ akẹ́kọ̀ọ́ sọ́nà láti sọ̀rọ̀ lórí oríṣiríṣi orí ọ̀rọ̀ tí ó lè mú wọn lo àkànlò èdè tí a kọ́ wọn<br>2. Fi àwọn àkànlò èdè tí a kọ sára káàdì han akẹ́kọ̀ọ́<br>3. ṣe àlàyé ìtumọ̀ wọn | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí oríṣiríṣi ìlò àti ìtumọ̀ àkànlò èdè nínú gbólóhùn<br>2. kọ oríṣiríṣi àkànlò èdè sínú ìwé | • àtẹ àkànlò èdè àti ìtumọ̀ rẹ̀<br>• káàdì aláfihàn tí a kọ àkànlò èdè sí<br>• pátákó ẹlẹ́mọ̀ọ́ | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò:<br><br>Sọ oríṣiríṣi àpẹẹrẹ àkànlò èdè |
| **Oríṣiríṣi òwe Yorùbá** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. pa òwe<br>2. ṣe àlàyé ìtumọ̀ wọn | 1. òwe àti pàtàkì rẹ̀<br>2. oríṣiríṣi òwe<br>3. ìtumọ̀ oríṣiríṣi òwe tí akẹ́kọ̀ọ́ pa | 1. sọ ohun tí òwe jẹ́ àti pàtàkì rẹ̀<br>2. pe akẹ́kọ̀ọ́ láti pa òwe tí wọ́n ti gbọ́ rí<br>3. kọ àwọn òwe náà sí ara pátákó ìkọ̀wé<br>4. ṣe àfikún àwọn òwe tirẹ̀<br>5. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti sọ ìtumọ̀ àwọn òwe náà kí ó ṣe àlàyé àkókò tí a má a ń lò ó | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́<br>2. pa àwọn òwe tí o mọ̀<br>3. sọ ìtumọ̀ àwọn òwe tí ó pa<br>4. sọ àkókò tí à ń lo àwọn òwe náà<br>5. ṣe àkọsílẹ̀ àwọn òwe tí olùkọ kọ sí ara pátákó | • téèpù tí a ti gba òwe sí<br>• oríṣiríṣi àwòrán nípa òwe tí a pa | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>1. pa òwe méta<br>2. ṣe àlàyé àkókò tí a má a ń lo àwọn òwé náà |
| **Àatò ewì** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. ṣe àlàyé àwọn ìgbésẹ̀ ṣíṣẹ̀ n tẹ̀lé inú ewì<br>2. ṣe àlàyé àwọn ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín àwọn ìgbésẹ̀ inú ewì | 1. àatò ewì<br>2. kín ni àatò ewì b.a<br>- ìbẹ̀rẹ̀<br>- àarín<br>- ìparí<br>3. títẹ téèpù/ CD tí a gba ewì sí | 1. ṣàlàyé àatò ewì b.a<br>- ìbẹ̀rẹ̀<br>- àárín<br>- ìparí<br>2. tẹ téèpù/CD tí a gba ewì sí sétígbọ̀ ọ́ akẹ́kọ̀ọ́ | 1. tẹ̀tí sí àlàyé olùkọ́ lórí àatò ewì<br>2. tẹ́tí sí téèpù/CD tí a gba ewi sí<br>3. lo àwọn ìgbésẹ̀ ṣíṣẹ̀ n tẹ̀lé tí olùkọ́ kọ́ wọn láti fi pín ewì kan | téèpù/CD tí a gba ewì sí | - Kí akẹ́kọ̀ọ́ lo àwọn ìgbésẹ̀ ṣíṣẹ̀ n tẹ̀lé tí olùkọ́ kọ́ wọn fi kọ ewì kan.<br>- ṣàlàyé ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín àwọn ìgbésẹ̀ náà |

KÓKÓ Ọ̀RỌ̀ : ÈDÈ -Ọ̀RỌ̀ LÁMÈYÍTỌ̀ LÓRÍ LÍTÍRÉṢỌ̀ IPELE KẸTA APÁ KEJÌ

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **ṣíṣe eré níṣe/onítàn** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè ṣe eré oníṣe/onítàn láṣeyege | 1. yíyan ìwé eré oníṣe/onítàn kan<br>2. ṣíṣe eré inú ìwé eré oníṣe/onítàn náà<br>3. àtúnsọ ìtàn eré oníṣe/onítàn náà ní ṣókí<br>4. ẹ̀dá ìtàn eré àti ìwà wọn<br>5. ẹ̀kọ́ inú eré oníṣe/on ítàn náà | 1. yan ìwé eré oníṣe kékeré kn tí ó kún fún ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí<br>2. Darí kíka ìwé oníṣe/onítàn náà ní kíláàsì<br>3. Darí fífi ìwé eré oníṣe/onítàn náà ṣeré<br>4. Darí ìsọníṣókí ìtàn inú eré náà ní kíláàsì<br>5. Darí ìjíròrò lórí kókó ẹ̀kọ́ tí ó súyọ nínú eré náà | 1. ka ìwé eré oníṣe/onítàn tí olùkọ́ yàn<br>2. Kópa nínú eré oníṣe/onítàn náà<br>3. Kópa nínú ìsọníṣókí<br>4. Kópa nínú ìjíròrò nípa ẹ̀kọ́ tí ó súyọ nínú ìtàn eré náà<br>5. kópa nínú ìjíròrò lórí ẹ̀dá ìtàn inú eré náà àti ìhùwàsí wọn | Ohun èlò ìṣeré | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. dárúkọ olú ẹ̀dá ìtàn eré náà<br>2. Sọ àwọn ẹ̀kọ́ tí ó kọ́ nípa eré oníṣe/onítàn tí ó kà |

**KÓKÒ ỌRỌ: ÌTÀN ÀRÒSỌ ỌLỌRỌ GEERE** **IPELE KẸTA** **APÁ KEJÌ**

**KÓKÓ ỌRỌ KÉKÈKÉ : KÍKA ÌWÉ ÌTÀN ÀRÒSỌ ỌLỌRỌ GEERE**

| **ORÍ ỌRỌ** | **ÈRÒÑGBÀ** | **ÀKÓÓNÚ IṢẸ́** | **ÀMÚṢE IṢẸ́** | | **OHUN ÈLÒ ÌKỌNI** | **ÌTỌNISỌNÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌN** |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | **OLÙKỌ** | **AKẸ́KỌ̀Ọ́** | | |
| **Ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. ka Ìwé tí a bá yàn geere<br>2. fún ìtàn inú ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere náà sọ já gaara | 1. kíka ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere tí a yàn<br>2. títún ìtàn inú ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere náà sọ | 1. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti ka ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere<br>2. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti tún ìtàn inú ìwé àròsọ ọlọ́rọ̀ geere sọ | 1. ka ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere ní àkàyé<br>2. tún ìtàn ìwé àròsọ ọlọ́rọ̀ geere sọ | Àwọn ìwé tí a yàn | 1. kí akẹ́kọ̀ọ́ ka ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere sísta<br>2. kí akẹ́kọ̀ọ́ tún ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere sọ sísta |

**KỌ́KỌ́ Ọ̀RỌ̀: ÌṢỌWỌ́KỌ̀WÉ** **IPELE KẸTA** **APÁ KEJÌ**

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | **OLÙKỌ́** | **AKẸ́KỌ̀Ọ́** | | |
| **Ìtẹ̀síwájú lórí ìfàmìsí 11** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. dá oríṣiríṣi àkọtọ́ (àmì) mọ̀<br>2. ṣe àmúlò rẹ̀ bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ | Oríṣiríṣi àkọtọ́ (àmì) b.a<br>i. àmì kọ́lọ́ọ̀nù (:)<br>ii. àmì àdàmodi kọ́lọ́ọ̀nù (;)<br>iii. ìdánudúró (.)<br>iv. ìdánudúrodíẹ (,) | 1. ṣàlàyé oríṣiríṣi àkọtọ́ (àmì) àti ìlò wọn<br>2. kọ wọ́n sí ara pátákó<br>3. tọ́ akẹ́kọ̀ọ́ sọ́nà láti kọ àwọn àmì náà sára pátákó | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́<br>2. kópa nínú kíkọ sí ara pátákó<br>3. kọ àkọsílẹ̀ ara pátákó sínú ìwé rẹ̀ | Káàdì pélébé-pélébé tí a kọ àwọn àkọtọ́ (àmì) sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. ṣe ìdámọ̀ àwọn àkọtọ́ (àmì) tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó.<br>2. kọ àkọsílẹ̀ kí ó àwọn àmì wọ̀nyí sì ṣe àmúlò |
| **Ìdánwò lórí sípẹ́lì** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. Sípẹ́lì ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn Yorùbá ní àkọtọ́<br>2. Fi àmì Yorùbá sórí ọ̀rọ̀/ gbólóhùn Yorùbá tí a bá pè | 1. Sípẹ́lì ẹyọ ọ̀rọ̀<br>2. Àpèkọ oríṣiríṣi gbólóhùn | 1. Pe àpèkọ ẹyọ ọ̀rọ̀ fún akẹ́kọ̀ọ́ láti sípẹ́lì<br>2. Pe àpèkọ oríṣiríṣi gbólóhùn fún akẹ́kọ̀ọ́ láti sípẹ́lì<br>3. Bu ọwọ́ sí ìwé akẹ́kọ̀ọ́<br>4. Darí akẹ́kọ̀ọ́ láti ṣe àtúnṣe àpèkọ sípẹ́lì náà sí ara pátákó | 1. Kọ sípẹ́li àpèkọ ẹyọ ọ̀rọ̀ tí olùkọ́ pè fún wọn sínú ìwé wọn<br>2. Kọ oríṣiríṣi gbólóhùn tí olùkọ́ pè fún wọn sínú ìwé wọn<br>3. ṣe àtúnṣe àwọn ọ̀rọ̀ gbólóhùn tí ó ṣì sínú ìwé wọn | Káàdi/kádíbọ́ọ̀dù aláfihàn tí a kọ ẹyọ ọ̀rọ̀ àti oríṣiríṣi gbólóhùn sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́: ṣe àtúnṣe àwọn ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí a pè fún un tí ó ṣì |
| **Iṣẹ́ ọ̀nkọ̀wé alátinúdá** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. sọ gbogbo ìlapa èrò ní ṣíṣẹ̀ n tẹ̀lé<br>2. ṣe àlàyé àwọn ìlapa èrò yìí | 1. kíkọ oríṣiríṣi àròkọ àti ààtò wọn. bí àpẹẹrẹ:<br>- ìfáàrà<br>- ìlapa èrò<br>- ààrín<br>Títo kókó ní ṣíṣẹ̀ n tẹ̀lé Àgbálọgbábọ̀<br>2. àròkọ lórí oríṣiríṣi ohun èlò b.a<br>- inú ilé<br>- ilé ẹ̀kọ́<br>- ààrín ìlú<br>3. àdàkọ àwọn ohun tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó sínú ìwé wọn | 1. ṣàlàyé kíkún lórí oríṣiríṣi àròkọ àti ààtò wọn<br>2. ṣàlàyé kíkún lórí ohun èlò tí a gbésíwájú akẹ́kọ̀ọ́<br>3. kọ àwon ìlapa èrò sí ara pátákó ní ṣíṣẹ̀ n tẹ̀lé nípa àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí a ti ṣàlàyé:<br>- ohun èlò inú ilé<br>- ohun èlò ilé ẹ̀kọ́<br>- ohun èlò ààrín ìlú | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́<br>2. ṣe àdàkọ àwọn ìlapa èrò tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó sínú ìwé wọn | Àwòrán àwọn ohun èlò tó bá orí àròkọ mu | Kí akẹ́kọ̀ọ́ kọ gbogbo ìlapa èrò ní ṣíṣẹ̀ n tẹ̀lé |

**KÓKÒ ỌRỌ̀ẸKỌ NÍPA ÌṢỌWỌ́KỌWÉ**

**KÓKÓ ỌRỌ̀ KÉKÈKÉ: ÌTẸ̀SÍWÁJÚ KÍKA ORÍṢIRÍṢI ÀMÌ ÀTI OHUN TÍ A KỌ SÍ ARA PÁTÁKÓ AJÚWE IPELE KẸTA APÁ KEJI**

`

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Kíka oríṣiríṣi àmì àti pátákó ajúwe** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. ka oríṣiríṣi àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe | 1. ṣíṣe àfihàn oríṣiríṣi àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe<br>2. kíka àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe tí a ṣàfihàn | 1. ṣe àfihàn oríṣiríṣi àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe<br>2. darí kíka àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó inú àwòrán tí a ṣàfihàn | 1. wo oríṣiríṣi àwòrán àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe tí olùkọ́ ṣe àfihàn<br>2. kíka àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe tí olùkọ́ ṣàfihàn tí ó sì ti wò | Àtẹ àwòrán àwọn àmì àti ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe | Ka àwọn àmì tí a ṣe àfihàn rẹ̀ nínú àtẹ àwòrán |

**KÓKÒ Ọ̀RỌ̀: Ẹ̀KỌ́ NÍPA ÀWỌN ÌRÓ ÈDÈ YORÙBÁ** **IPELE KẸTA** **APÁ KEJÌ**

| **ORÍ Ọ̀RỌ̀** | **ÈRÒŃGBÀ** | **ÀKÓÓNÚ IṢẸ́** | **ÀMÚṢE IṢẸ́** | | **OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI** | **ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N** |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | **OLÙKỌ́** | **AKẸ́KỌ̀Ọ́** | | |
| **ẹ̀kọ́ nípa ìpàrójẹ àti ìsúnkì** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. ṣe àlàyé nǹkan tí àrànmọ́ jẹ́<br>2. kanàwọn ọ̀rọ̀ méjì nípa ìgbésẹ̀ àrànmọ́ | 1. àrànmọ́ ọ̀rọ̀ méjì b.a<br>- ara+ ìlú di aráàlú<br>- ilé+ìwé di iléèwé<br>- ọjà+ọba di ọjàaba<br>2. àrànmọ́ láàárín ọ̀rọ̀ kan. b.a<br>-egigun di eigun<br>-òrìṣà di òìṣà/òòṣà | Kọ àpẹẹrẹ sí ojú pátákó yóò sì ṣe àlàyé àrànmọ́ | 1. tẹ́tí sí àlàyé lórí àrànmọ́<br>2. sọ àpẹẹrẹ tirẹ̀ | Káàdìbọ̀ọ̀dù tí a kọ àpẹẹrẹ sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́ kọ:<br><br>1. ẹyọ ọ̀rọ̀ mẹ́ta tí a ti ṣe ìsúnkì<br>2. àwọn ọ̀rọ̀ mẹ́ta tí a kàn pọ̀ nípa ìgbésẹ̀ àrànmọ́ |

KỌ́KỌ̀ Ọ̀RỌ̀: Ọ̀RỌ̀- ÈDÈ, ÌDÁNMỌ̀RÁN ÀTI ÀKÀYÉ IPELE KẸTA APÁ KEJÌ

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÓŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Ìró Yorùbá tí ó ń gba àmì ohùn** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè lo àmì ohùn (ìró èdè) mẹ́tẹ̀ẹ̀ta sórí ọ̀rọ̀ Yorùbá bí ó ti yẹ | 1. Àtúnyẹ̀wò àlàyé lórí oríṣi ohùnYorùbá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ati àmì wọn<br>2. Àlàyé lórí àwọn lẹ́tà tí ó ń gba àmì lórí B.a : à,a,á, é, e, è àmì ohùn lórí àránmú oníṣílébù kan. b.a:<br>- kọ̀ǹkọ̀<br>- gbangba<br>- kóńkó<br>- pẹnpẹ abbl | 1. ṣe àtúnyẹ̀wò àlàyé lórí oríṣi ohùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta àti àmì wọn<br>2. ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn lẹ́tà tí ó ń gba àmì lórí | ẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí oríṣi ohùn àti àmì wọn<br>2. tẹ́tí síɔẹ̀ gbọ́ àlàyé olùkọ́ lórí àwọn lẹ́tà tí ó ń gba àmì lórí | Káàdì aláfihàn tí a kọ àmì ohùn Yorùbá sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. Kọ àpẹẹrẹ àmì ohùn Yorùbá tí olùkọ́ pè fún wọn sí ara pátákó<br>2. Mẹ́nu ba àwọn lẹ́tà Yorùbá tí ó ń gba àmì lórí sí ara pátákó<br>3. ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ohun tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó sínú ìwé wọn |
| **Ìtẹ̀síwájú lórí àkàyé àti àwọn ìbéèrè tí ó tẹ̀lé e** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. Ka ìwé àṣàyàn ní àkàyé<br>2. Dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó súyọ nínú àkàyé náà | 1. Kíka àyọkà tí a yàn ní àkàyé<br>2. Dídáhùn ìbéère tí ó súyọ nínú àyọkà. B.a<br>-ìtọ́jú ara ẹni<br>-àǹfààní,àṣìlò oògùn<br>-ewu inú àṣìlò oògùn | 1. yan àyọkà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́<br>2. Darí kíka àyọkà<br>3. Darí dídáhùn àwọn ìbéèrè tí ó súyọ nínú àyọkà<br>4. ṣe àlàyé àwọn ọ̀rọ̀ èdè àmúlò àti ọ̀rọ̀ mìíràn tí ó ta kókó tí ó súyọ nínú àyọkà | 1. Ka àṣàyàn àyọkà ní àkàyé<br>2. Dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó súyọ nínú àyọkà<br>3. Tẹ́tí sí àlàyé tí olùkọ́ ṣe lórí àwọn ọ̀rọ̀ èdè àmúlò àti ọ̀rọ̀ mìíràn tí ó ta kókó tí ó súyọ nínú àyọkà | • Ìwé àyọkà<br>• Àwòrán àwọn ohun tí ó jẹ mọ́ àyọkà<br>• B.a<br>-dọ́kítà: oògùn, nọ́ọ̀sì, aláìsan, abẹ́rẹ́ | 1. ka a[yọkà lórí ìtọ́jú aláboyún,aláìsàn ibà,àìsàn kògbóògùn<br>2. dáhùn àwon ìbéèrè tí ó súyọ nínú àyọkà lórí ìtọ́jú ara ẹni, ṣíṣe àmúlò oògùn, ṣíṣi oògùn lò àti ewu tó rọ̀ mọ́ ọn |

| ORÍ ỌRỌ | ÈRÒǸGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌNI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>ṣàlàyé àwọn ọgbọ́n tí a fi ń ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ | ṣíṣàlàyé àwọn ọgbọ́n tí a fi ń ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀. b.a:<br>- àmúlò ààrọ̀<br>- àmúlò àyípadà ìhun gírámà<br>- àmúlò àyípadà ìrísí ọ̀rọ̀ | 1. ṣàlàyé àwon ọgbọ́n àmúlò fún àgbékalẹ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀<br>2. ṣe àmúlò àtẹ tí ó ṣe àfihàn gbólóhùn àti ọgbọ́n àgbékalẹ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ ketekete | Tẹ́tí sí àlàyé ọgbọ́n àgbékalẹ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ tí olùkọ́ ṣe | Àtẹ tí ó ń ṣe àfihàn gbólóhùn àti ẹ̀dà òye ọ̀rọ rẹ̀ | Kí akẹ́kọ̀ọ́ sọ ogbọ́n àgbékalẹ̀ ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ méjì tí ó mọ |
| **Àpẹẹrẹ àwọn àyọkà ṣókí** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. ka àyọkà geere<br>2. sọ ohun tí ó kà nínú àyọkà ní ṣókí<br>3. dáhùn àwọn ìbée[rè lórí àyọkà tí ó kà | 1. àgbe]yẹwò ìtumọ̀ "ṣókí"<br>2. kíka àwon àyọkà nínú ìwé àsàyàn<br>3. àlàyé lórí àyọkà náà<br>4. sísọ ìtàn inú àwọn àyọkà ní ṣókí<br>5. dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó tẹ̀lé àyọkà náà | 1. ṣe àgbéyẹ̀wò ìtumọ̀ "ṣókí"<br>2. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti ka àyọkà nínú ìwé àṣàyàn<br>3. ṣe ìjíròrò lórí àyọkà náà pẹ̀lú akẹ́kọ̀ọ́<br>4. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti sọ ìgbésẹ̀ tí wọn yóò fi sọ àyọkà náà ní sókí<br>5. pe akẹ́kọ̀ọ́ mélòó kan láti sọ ìtàn náà ní ṣókí | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ìtumọ̀ "ṣókì"<br>2. kópa nínú kíka àyọkà láti inú ìwé àṣàyàn<br>3. kópa nínú ìjíròrò lórí àyọkà náà<br>4. ṣàlàyé àwọn ìgbésẹ̀ tí yóò lò fi sọ àyokà ní ṣókí<br>5. kópa nínú sísọ ìtàn ní ṣókí | • àwòrán tí ó bá èrò inú àyọkà tí a yàn mu<br>• káàdì aláfihàn tí a kọ àwon ọ̀rọ̀ tuntun inú àyọkà sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́ sọ itàn kan ní ṣókí sínú ìwé wọn |
| **Èdè àmúlò** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>sọ oríṣiríṣi oníṣẹ́ ìjọba àti èdè àmúlò wọn | 1. oríṣiríṣi oníṣẹ́ ìjọba. b.a oníṣègùn, dọ́kítà, àdájọ́, onímọ̀ ẹ̀rọ, olùkọ́<br>2. oríṣiríṣi èdè àmúlò àwon oníṣẹ́ ìjọba náà | 1. ṣe àfihàn fídíò oríṣirísí on ìṣẹ́ ìjọba<br>2. sọ oríṣiríṣi èdè àmúlò àwọn oníṣẹ́ ìjọba náà | 1. wo àwòrán fídíò oríṣiríṣi oníṣẹ́ ìjọba<br>2. tẹ́tí sí oríṣiríṣi èdè àmúlò àwọn oníṣẹ́ ìjọba tí olùkọ́ sọ | • àwòrán /fídíò<br>• àtẹ tí a kọ oríṣiríṣi iṣẹ́ ìjọba sí àti èdè àmúlò wọn | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. dárúkọ oríṣìí iṣẹ́ ìjọba márùn ún tí ó mọ̀ |

| ORÍ ỌRỌ | ÈRÒǸGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌNI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLẸ́WỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| | | a. dọ́kítà – oògùn, abẹ́rẹ́<br>b. olùkọ́ – ìwé, kíláàsì, ẹfun àti pátákó ìkọ̀wé | 3. darí ìjíròrò lórí oríṣiríṣi iṣẹ́ ìjọba síwájú sí i àti èdè àmúlò wọn | 3. kópa nínú ìjíròrò lórí oríṣiríṣi iṣẹ́ ìjọba síwájú sí i àti èdè àmúlò wọn | | 2. sọ èdè àmúlò méjìméjì fún iṣẹ́ ìjọba mẹ́ta péré nínú àwọn tí ó ti dárúkọ |
| **Òǹkà Yorùbá**<br><br>**(1500 -2000)** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. ka òǹkà láti ẹgbèrún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ[tà dé ẹgbàá<br>2. dá òǹkà mọ̀ láti ẹgbèrún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta dé ẹgbàá | 1. kíka òǹkà láti ẹgbẹ̀rún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta dé ẹgbàá<br>2. àlàyé kíkún nípa òǹkà<br>Àpẹẹrẹ:<br>1,600 - ẹgbẹ̀jọ<br>=igba mẹ́jọ<br>(200X8)<br>1700 -ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀sán<br>= (200X9)<br>1900 -ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀wà<br>(200X9)<br>2000 -ẹgbàá<br>(200X10)<br>Igba mẹ́wàá | 1. tọ́ akẹ́kọ̀ọ́ sọ́nà láti ka òǹkà láti ẹgbẹ̀rún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta dé ẹgbàá<br>2. ṣe àlàyé ìgbésẹ̀ òǹkà ní kíkún | 1. ka òǹka[ láti ẹgbèrùn lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ[ta dé ẹgbàá<br>2. dá òǹkà tí a kọ sí ara pátákó mọ̀ ní ọ̀kọ̀ọ̀kan<br>3. kọ òǹkà tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó sínú ì é | • kádi]bọ́ọ̀dù tí a kọ òǹkà láti ẹgbèrún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta dé ẹgbàá<br>• káàdì pélébé pélébé tí a kọ òǹkà kọ̀ọ̀kan sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́ :<br>1. ka òǹkà láti ẹgbèrún lé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta dé ẹgbàá<br>2. kọ òǹka tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó |

**KÓKÒ ỌRỌ: ỌRỌ- ÈDÈ, ÌDÁNMỌRÁN ÀTI ÀKÀYÉ** **IPELE KẸTA** **APÁ KEJÌ**

**KÓKÒ ỌRỌ KÉKÈKE: SÍSỌ**

| ORÍ ỌRỌ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌNI | ÌTỌNISỌNÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌN |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Orúkọ Yorùbá** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>Sọ oríṣiríṣi orúkọ Yorùbá àti àlàyé nípa ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ ẹ | oríṣiríṣi orúkọ Yorùbá àti àlàyé nípa ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ ẹ. àpẹẹrẹ:<br>i. **orúkọ àbíso**<br>Olúyẹ́misí, Káyọ̀dé, Adédayọ̀, Olúfẹ́mi<br>ii. **orúkọ àmútọ̀runwá**<br>Táyé, Ìdòwú, Ìgè, Òjó, Àìná<br>iii. **orúkọ ìdílé**<br>Ògúndáre<br>Àyàngbayì<br>Òòṣàgbèmí | 1. pe akẹ́kọ̀ọ́ láti sọ oríṣiríṣi orúkọ tí wọ́n mọ̀<br>2. kọ àwọn orúkọ náà sí ara pátákó ìkọ̀wé<br>3. pín àwọn orúkọ náà sí ìsọ̀rí tí wọ́n bá mu gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe wà lábẹ́ àkóónú iṣẹ́ | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí àwọn orúkọ Yorùbá<br>2. kọ àwọn orúkọ náà ní ìsọ̀rí ìsọ̀rí sí inú ìwé wọn gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ ṣe kọ ọ́ sára pátákó ìkọ̀wé | • pátákó ẹlẹ́mọ̀ọ́<br>• káàdì pélébé-pélébé tí a kọ àwọn orùkọ Yorùbá sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. sọ ìpínsísọ̀rí àwọn orúkọ tí Yorùbá ń jẹ́<br>2. sọ ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ irú orúkọ bẹ́ ẹ̀<br>3. ṣe ìwádìí àwọn orúkọ mìíràn bọ̀ láti ilé |
| **Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀**<br><br>**(ìtẹ̀síwájú)** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>ṣe àlàyé kíkún àti àpẹẹrẹ lórí<br>1. ọ̀rọ̀ ìṣe<br>2. ọ̀rọ̀ àpọ́nlé | Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀:<br><br>Eékì ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan<br>1. ọ̀rọ̀ ìṣe<br>2. ọ̀rọ̀ àpọ́nlé | 1. ṣe eékì ìsọ̀rí ọ̀rọ̀<br>2. kọ àpẹẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀ tí ó lè wà lábẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan. bí àpẹẹrẹ<br>i. **ọ̀rọ̀ ìṣe**<br>jẹ,rà,tà,jí,wẹ,jókòó<br>ii. **ọ̀rọ̀ àpọ́nlé**<br>kíákíá, fòò,fiofio abbl | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan<br>2. kọ àwọn àpẹẹrẹ tí olùkọ́ kọ sókè<br>3. pe àwọn ọ̀rọ̀ náà bí olùkọ́ ṣe pè é fún wọn | Káďíbọ́ọ̀dù àti<br><br>Káàdì pélébé pélébé | Kí akẹ́kọ̀ọ́ tọ́ka sí irúfẹ́ ọ̀rọ̀ tí ó wà lábẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan nínú gbólóhùn kéékèèkéé tí olùkọ́ kọ sójú pátákó |

**KỌ́KỌ̀ ỌRỌ̀:ÌDÁNMỌ̀RÁN, ỌRỌ̀ ÈDÈ ÀTI ÀKÀYÉ** **IPELE KETA** **APÁ KẸTA**

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Àkàyé: ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ọmọ Yorùbá** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. sọ ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ọmọ Yorùbá<br>2. ṣe àlàyé bí wọ́n ṣe tàn kálẹ̀ dé ibi tí wọ́n wà lónìí<br>3. sọ nípa àwọn ọmọ Odùduwà<br>4. ṣàlàyé ìpínlẹ̀ tí a ti lè rí ọmọ Yorùbá b.a<br>5. Ọ̀yọ́, Ondó,Ògùn,Ọ̀ṣun,Èkìti abbl | 1. Kíka ìwé àṣàyàn tó dálé ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ọmọ Yorùbá<br>2. Ìsọníṣókí ìtàn<br>3. Ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá láti ọ̀dọ̀ Odùduwà<br>4. Àwọn ọmọ Odùduwà àti ibi tí wọ́n tẹ̀dó sí | 1. Jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ka àkàyé nípa ìṣẹ̀dálẹ̀ ọmọ Yorùbá<br>2. ṣàlàye àwọn àgbègbè tí ẹ̀yà Yorùbá tàn dé ní àgbáyé<br>3. fi ìtàn àti àwòrán ṣe àlàyé bí Yorùbá ṣe ṣè àti bí wọ́n ṣe dé ibi tí wọ́n wà báyìí (oríṣun Yorùbá)<br>4. ṣàlàyé nípa ọmọ Odùduwà àti ibi tí wọ́n tẹ̀dó dé | 1. ka àyọkà nípa ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ọmọ Yorùbá<br>2. dárúkọ díẹ̀ lára àwọn agbègbè tí ẹ̀yà yorùbá tàn dé<br>3. sọ lérèfé ibi tí Yorùbá tàn kálẹ̀ dé<br>4. dárúkọ oríru àwọn Yorùbá | • Máàpù Áfíríkà àti ilẹ̀ Lárúbáwá<br>• Máàpù Nàìjíríà<br>• Máàpù Àgbáyé | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. Dàrúkọ àwọn ìpínlẹ̀ tí ọmọ Yorùbá wà<br>2. Dárúkọ èdè àdúgbò wọn<br>3. Kọ orúkọ àwọn orílẹ̀ èdè tí Yorùbá tàn dé lágbàáyé |
| **Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ èdè Yorùbá: ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. Sọ ohun tí ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ jẹ́<br>2. Sọ oríṣiríṣi ọ̀nà tí a ń gbà dá ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ mọ̀ nínú gbólóhùn | 1. Kí ni ọ̀rọ̀ orúkọ?<br>2. Kí ní ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ<br>3. Àlàyé kíkún lórí ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ̀pò pẹ̀lu àpẹẹrẹ | 1. ṣe àlàyé ohun tí ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ jẹ́<br>2. ṣe oríṣiríṣi àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ<br>3. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti ṣe ìdámọ̀ ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ nínú gbólóhùn<br>4. jẹ́ kí ákẹ́kọ̀ọ́ lo ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ díẹ̀ ní gbólóhùn<br>5. jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ṣe àkọsílẹ̀ ohun tí ó wà ní ara pátákó sínú ìwé wọn | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí èèkì ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ<br>2. tẹ̀lé ìtọ́ni olùkọ́ láti sọ oríṣiríṣi àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ<br>3. ṣe ìdámọ̀ ọ̀rọ̀ orúkọ nínú gbólóhùn<br>4. lo ọ̀rọ̀ orúkọ àti arọ́pò orúkọ ní gbólóhùn<br>5. ṣe àkọsílẹ̀ ohun tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó ìkọ̀wé sínú ìwé wọn | Kádíbọ́ọ̀dù tí a kọ oríṣiríṣi àpẹẹrẹ sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́ sọ:<br>1. ọ̀rọ̀ orúkọ márùn ún<br>2. lo ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ márùn ún ní gbólóhùn |

**KỚKÒ ỌRỖ:ÌDÁNMỌRÁN, ỌRỌ ÈDÈ ÀTI ÀKÀYÉ** **IPELE KETA** **APÁ KẸTA**

| **ORÍ ỌRỌ** | **ÈRÒŃGBÀ** | **ÀKÓÓNÚ IṢẸ́** | **ÀMÚṢE IṢẸ́** | | **OHUN ÈLÒ ÌKỌNI** | **ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N** |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | **OLÙKỌ́** | **AKẸ́KỌ̀Ọ́** | | |
| **Ìtẹ̀síwájú lórí ọjọ́ nínú ọ̀sẹ̀ àti oṣù nínú ọdún** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. ka ọjọ tó wà nínú ọ̀sẹ̀ ní èdè Yorùbá<br>2. ṣàlàyé iye oṣù tó wà nínú ọdún<br>3. dá àwọn ọjọ́ àti oṣù wọ̀nyí mọ̀ nínú kàlẹ́ńdà | 1. àwọn ọjọ́ nínú ọ̀sẹ̀:<br>Sunday - àìkú<br>Monday - ajé<br>Tuesday - ìṣẹ́gun<br>Wednesday- ọjọ́ ru<br>Thursday - ọjọ́ bọ̀<br>Friday - ẹtì<br>Saturday - àbámẹ́ta<br>2. àwọn oṣù nínú ọdún<br>- ṣẹrẹ<br>- èrèlé<br>- ẹ̀rẹnà<br>- igbe<br>- Èbìbí<br>- Okúdù<br>- agẹmọ<br>- Ògún<br>- ọwẹ́wẹ̀<br>- ọ̀wàrà<br>- Belu<br>- ọ̀pẹ<br>3. àlàyé àti ìtàn nípa ọjọ́ àti oṣù nínú ọdún | 1. kọ àwọn ọjọ́ wọ̀nyí sí ara pátákó<br>2. kọ àwọn oṣù sí ara pátákó ìkọ̀wé<br>3. kọ wọ́n ní orin fún akẹ́kọ̀ọ́<br>4. pe akẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan láti sọ àwọn ọjọ́ àti oṣù wọ̀nyí kí wọ́n sì kọ ọ́ ní orin | 1. pe àwon ọjọ́ wọ̀nyí tẹ̀ lé olùkọ́<br>2. pe àwọn oṣù wọ̀nyí tẹ̀lé olùkọ́<br>3. ka ọjọ/oṣù wọ̀nyí nínú káàdì pélébé-pélébé<br>4. fi àwọn ọjọ́/oṣù wọ̀nyí kọrin bí olùkọ́ ṣe kọ wọ́n | • kàlẹ́ńdà<br>• káàdì pélébé-pélébé | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>1. fi àwọn ọjọ́ náà kọrin<br>2. dáhùn ìbéèrè nípa àwọn ọjọ́ tó wà nínú ọ̀sẹ̀ àti oṣù tó wà nínú ọdún |

**KỌ́KỌ̀ Ọ̀RỌ̀:ÌDÁNMỌ̀RÁN, Ọ̀RỌ̀ ÈDÈ ÀTI ÀKÀYÉ** **IPELE KETA** **APÁ KẸTA**

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÒǸGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Èdè àmúlò: iṣẹ́ àmúṣe** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. dárúkọ oríṣiríṣi iṣẹ́ tí Yorùbá ń ṣe<br>2. sọ bí a ṣe ń kíni lẹ́nu iṣẹ́ | 1. iṣẹ́ Yorùbá<br>2. bí a ṣe ń kí ni lẹ́nu iṣẹ́ b.a akọ̀pẹ - ìgbà a ró<br>oníṣòwò- ajé a wọgbá<br>babaláwo – àbọrúbọyè<br>ọdẹ - àrèpa ògún | 1. darí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti dárúkọ iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan tí àwọn Yorùbá ń ṣe<br>2. sọ bí a ṣe ń kí òṣìṣẹ́ kọ̀ọ̀kan lẹ́nu iṣẹ́ wọn<br>3. kọ oprin ní oríṣiríṣi àti bí a ṣe ń kí ni sí ara pátákó<br>4. fi èyí ṣe eré nínú kíláàsì<br>5. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti ṣe àkọsílẹ̀ rẹ̀ | 1. dárúkọ díẹ̀ lára àwọn iṣẹ́ tí Yorùbá má a ń ṣe<br>2. ṣàlàyé ikíni àwọn òṣìṣẹ́ kọ̀ọ̀kan bí olùkọ́ ṣe sọ ọ́<br>3. ṣe eré iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan àti ìkíni wọn | oríṣiríṣi ohun èlò tí a fi ń ṣe iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. Dárúkọ oríṣiríṣi iṣẹ́ mẹ́fà tí Yorùbá máa ń ṣe<br>2. Sọ bí a ṣe ń kí òṣìṣẹ́ kọ̀ọ̀kan lẹ́nu iṣẹ́ |

**KÓKÓ ỌRỌ : ÈDÈ - ỌRỌ LÁMÈYÍTỌ LÓRÍ LÍTÍRÉṢỌ** **IPELE KẸTA** **APÁ KẸTA**

| ORÍ ỌRỌ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Àkànlò èdè** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè lo oríṣiríṣi àkànlò èdè nî gbólóhùn | 1. Ìlo oríṣiríṣi àkànlò èdè nínú gbólóhùn. B.a<br>- olè náà <u>fesè</u> <u>fe</u><br>- Kábìyèsì <u>wàjà</u> abbl<br>2. Ìlo káàdì tí a kọ àwọn àkànlò èdè sí<br>3. Ìlo àtẹ àkànlò èdè | 1. béèrè nípa àwọn àkànlò èdè tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti kọ́<br>2. tọ́ akẹ́kọ̀ọ́ sọ́nà láti lo oríṣiríṣi àkànlò èdè nî gbólóhùn | 1. sọ oríṣiríṣi àwọn àkànlò èdè tí ó ti kọ́<br>2. lo oríṣiríṣi àkànlò èdè náà nî gbólóhùn | • àtẹ àkànlò èdè àti ìtumọ̀ rẹ̀<br>• káàdì aláfihàn tí a kọ àkànlò èdè sí<br>• pátákó ẹlẹ́mọ̀ọ́ | Kí akẹ́kọ̀ọ́ lo àkànlò èdè tí olùkọ́ bá fún wọn nî gbólóhùn |
| **Ìlò òwe** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè sọ oríṣiríṣi ìlò òwe. b.a:<br>- òwe akọ́mọníwà rere<br>- òwe tí a fi ń dẹ́kun ìwà búburú<br>- oríṣiríṣi òwe dorúkọ<br>- oríṣiríṣi ìtàndòwe | 1. oríṣiríṣi òwe<br>2. ìlò òwe b.a<br>- òwe akọ́mọníwà rere<br>- òwe tí a fi ń dẹ́kun ìwà búburú<br>3. oríṣiríṣi òwe dorúkọ<br>4. oríṣiríṣi ìtàndòwe b.a<br>- oore nigún ṣe tó fi pá lórí, oore làkàlàmàgbò ṣe tó fi yọ gẹ̀gẹ̀ , oore ni àgbàkùrà ṣe tí ẹni dúdú fi di funfun<br>- ìjàpá àti ìgbín:<br>Àlọ ni tìjàpá àbọ̀ ni ti àǹà rẹ̀ | 1. ṣàlàyé oríṣirişi ìlò òwe b,a<br>òwe dorúkọ<br>- Abáyọ̀mí<br>- ṣàṣà ènìyàn<br>- òjò bá rọ̀<br>- ilésanmí dùn joyè<br>òwe akọ́mọníwà:<br>- ìwà rere<br>- dẹ́kun ìwà búburú<br>- mẹ́nuba àwọn ìtàndòwe Yorùbá | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí oríṣiríṣi ọ̀nà tí à ń gbà lo òwe<br>2. kópa nínu àpẹẹrẹ oriṣiríṣi ìlò òwe<br>3. kópa nínu sísọ àwọn ìtandòwe<br>4. kọ ìlò òwe tí olùkọ́ kọ sí ara pátákó sínu ìwé won | - téèpù tí a gba òwé sínu rẹ̀<br>- àwòrán oríṣiríṣi nípa àwọn òwe tí a pè | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. parí àwọn owe ti olùkọ sọ ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀<br>2. pa òwe tirẹ̀<br>3. sọ bí ọmọdé ṣe ń pa owe níwáju àgbà |

KOKO ỌRỌ : ÈDÈ - ỌRỌ LÁMÈYÍTỌ LÓRÍ LÍTÍRÉṢỌ IPELE KẸTA APÁ KẸTA

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **ọnà èdè àti ìṣọwọ́ lo èdè nínú ewì** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>tọ́kasí àwọn ọnà èdè àti ìṣọwọ́ lo èdè inú ewì | 1. kí ni ọnà èdè?<br>2. Oríṣiríṣi ọnà èdè b.a<br>- Àfiwé tààra<br>- Afiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́<br>- Àwítúnwí<br>- Afidípò<br>- Ìsọhundènìyàn<br>3. Kí ni ìṣọwọ́ lo èdè?<br>4. Àpẹẹrẹ oríṣiríṣi ìṣọwọ́ lo ọnà èdè b.a ìfọ̀rọ̀dárà, àwítúnwí:<br>- Ìró<br>- ẹyọ ọ̀rọ̀<br>- odindi gbólóhùn<br>- ìbádọ́gba gbólóhùn | 1. ṣàlàyé ohun tí ọnà èdè jẹ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ<br>2. ṣàlàyé ohun tí ìṣọwọ́ lo èdè jẹ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ<br>3. kíkọ ewì àṣàyàn sí ara káďíbọ́ọ̀dù<br>4. kíka ewì àṣàyàn ara káďíbọ̀ọdu sétìgbọ́ akẹ́kọ̀ọ́<br>5. dari àwọn akẹ̀kọ̀ọ́ láti tọ́ka sí àwọn ọnà èdè inú ewì náà<br>6. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti sọ ìṣọwọ́ lo èdè inú ewì náà<br>7. tẹ téèpù/CD sétìgbọ̀ ọ́ akẹ́kọ̀ọ́ | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ohun tí ọnà èdè jẹ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ wọn<br>2. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ohun tí ìṣọwọ́ lo èdè jẹ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ wọn<br>3. tẹ́tí sí ewì tí olùkọ́ ń kà láti inú káďíbọ́ọ̀dù<br>4. tọ́kasí àwọn ọnà èdè inú ewì náà<br>5. ṣàlàyé ọ̀nà ìṣọwọ́ lo èdè inú ewì náà<br>6. tẹ́tí sí ewì inú téèpù/Cd tí olùkọ́ tẹ̀ sétí wọn | 1. káďíbọ́ọ̀dù tí a kọ ewì sí<br>2. àwòrán ohun tí ewì dá lórí<br>3. téèpù/Cd tí a gba ewì kan sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. ka ewì kan pàtó<br>2. kí ó tọ́ka sí àwọn ọnà èdè àti ìṣọwọ́ lo ọnà èdè náà |
| **Ìjíròrò lórí ẹ̀kọ́ tí a rí kọ́ nínú ìtàn** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. Sọ oríṣiríṣi ẹ̀kọ́ tí wọ́n rí kọ́ nínú eré oníṣe/onítàn náà<br>2. Dáhùn àwọn ìbéèrè lórí eré oníṣe /onítàn náà | 1. mẹ́nuba ẹ̀kọ́ tí wọ́n kọ́ nínú eré oníṣe/onítàn kan<br>2. Ìjíròrò lórí àwọn ẹ̀kọ́ tí wọ́n rí kọ́ nínú eré náà | 1. Pe akẹ́kọ̀ọ́ láti fi eré tí wọ́n kà nínú ìwé ṣeré<br>2. Darí ìsọníṣókí ìtàn inú ìwé eré oníṣe náà<br>3. Darí ìjíròrọ̀ lórí kókó ẹ̀kọ́ tí ó sùyọ nínú eré náà | 1. Kópa nínú ìṣeré oníṣe/onítàn náà<br>2. Kópa nínú ìsọníṣókí ìtàn eré náà<br>3. Kópa nínú ìjíròrò lórí ẹ[kọ́ tí ó súyọ nínú ìtàn eré náà<br>4. Ko á nínú ìjíroro lórí ihùwàsí àwọn ẹ̀dá ìtàn inú eré náà | • Ohun èlò ìṣeré<br>• Akẹ́kọ̀ọ́ | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. Dárúkọ àwon ẹ̀dá ìtàn eré tí wọ́n ti kà<br>2. Jíròrò lórí ìhùwàsí mẹ́ta lára àwọn ẹ̀dá ìtàn náà<br>3. Sọ ẹ̀kọ́ méjì tí wọ́n rí kọ́ nínú ìtàn eré náà |

**KỌ́KỌ̀ ỌRỌ̀: ÌTÀN ÀRÒSỌ ỌLỌ́RỌ̀ GEERE** **IPELE KẸTA** **APÁ KẸTA**

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>1. fa ẹ̀kọ́ yọ nínú ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere tí ó kà<br>2. jíròrò lórí ìwúlò ẹ̀kọ́ náà fún àwùjọ | 1. síso àwọn ẹ̀kọ́ tí ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere kọ́wa<br>2. ìjíròrò lórí àwọn ẹ̀kọ́ náà fún àwùjọ<br>3. ṣe àfihàn àwọn iwé ìròyìn àtìgbàdégbà/àwòrán tí ó ṣe àfihàn àwọn ẹ̀kọ́ tí à ń kọ́ nínú ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere | 1. darí akẹ́kọ̀ọ̃ sọ àwọn ẹ̀kọ́ tí ìwéìtàn àròsọọlọ́rọ̀ geere kọ́ wa<br>2. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti jíròrò lórí àwon ẹ̀kọ́ náà fún àwùjọ | 1. Sọ àwọn ẹ̀kọ́ tí ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ geere kọ́ wa<br>2. Jíròrò lórí àwọn ẹ̀kọ̀ náà fún àwùjọ | Àwọn ìwé ìròyìn àtìgbàdégbà/ àwòrán tó ń ṣàfihàn àwọn ọ̀rọ̀ tí à ń kọ́ nínú ìwé ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere | Kí akẹ́kọ̀ọ́ ka ìwé ìtàn àròsọ kan, kí ó sọ ẹ̀kọ́ méta tí ó kọ́ nîbẹ̀, kí ó sì jíròrò lórí ìwúlò ẹ̀kọ́ náà fún àwùjọ |

KỌ́KỌ̀ Ọ̀RỌ̀: ÈRÒ NÍPA ÌṢỌWỌ́KỌ̀WÉ IPELE KẸTA APÁ KẸTA

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Ìdánrawò lórí àpèkọ àwọn ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí a yàn (tẹ̀síwájú)** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lẹ:<br>1. kọ àpèkọ ẹyọ ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí olùkọ́ pè fún un bí ó ti yẹ<br>2. fi àmì Yorùbá tí ó yẹ sórí ẹyọ ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí olùkọ́ pè fún un | 1. àpèkọ ẹ̀yọ ọ̀rọ̀ lóríṣiríṣi<br>2. àpèkọ oríṣiríṣi gbólóhùn | 1. pe àpèkọ ẹyọ ọ̀rọ̀ fún akẹ́kọ̀ọ́ láti kọ sílẹ̀<br>2. pe àpèkọ oríṣiríṣi gbólóhùn alábọ́dé fún akẹ́kọ̀ọ́ láti kọ sínú ìwé<br>3. ṣe àyẹ̀wò iṣẹ́ akẹ́kọ̀ọ́<br>4. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti ṣe àtúnṣe ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí a pè fún un | 1. kọ ẹyọ ọ̀rọ̀ tí olùkọ́ pè fún un sínú ìwé<br>2. kọ oríṣiríṣi gbólóhùn tí olùkọ́ pè fún un sínú ìwé<br>3. feti si àlayé olùkọ́ lórí àtúnṣe àpèkọ tí ó pè fún wọn<br>4. ṣe àtúnṣe àwọn ọ̀rọ̀/ gbólóhùn tí ó ṣì sínú ìwé | Káàdì/kádìbọ́ọ̀dù aláfihàn tí a kọ ẹyọ ọ̀rọ̀ àti oríṣiríṣi gbólóhùn sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>ṣe àtúnṣe àwọn ọ̀rọ̀ àti oríṣiríṣi gbólóhùn tí a pè fún un tí ó ṣì |
| **Iṣẹ́ òǹkọ̀wé alátinúdá** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. ṣe ìdánrawò nípa kíkọ oríṣiríṣi àròkọ<br>2. kọ oríṣiríṣi àròkọ nípa títẹ̀lé ìlapa èrò<br>3. lo èdè tó jínná láti fi kọ oríṣiríṣi àròkọ | 1. ìdánrawò nípa oríṣiríṣi àròkọ:<br>• alálàyé • oníròyìn<br>• alápèjúwe<br>2. ìdánrawò lórí oríṣiríṣi ohun èlò bí àpẹẹrẹ<br>inú ilé • ilé ẹ̀kọ́<br>• ààrín ìlú | Dán akẹ́kọ̀ọ́ wò:<br>1. lórí oríṣiríṣi àròkọ tí ó wà<br>2. lórí títẹ̀lé ìlapa èrò<br>3. lórí lílo èdè tó jinná láti fi kọ oríṣiríṣi àròkọ | 1. kí akẹ́kọ̀ọ́ tẹ́tí sí olùkọ́<br>2. kọ àròkọ lórí àwọn kókó tí olùkọ́ ti ṣe ìlapa rẹ̀ | Àwòrán àwọn ohun èlò tí ó bá orí àròkọ mu | Kí akẹ́kọ̀ọ́ kọ àròkọ ojú ìwé kan nípa ti ìlapa èrò mìíràn yàtọ̀ sí èyí tí olùkọ́ ṣe |
| **Kíka oríṣiríṣi àmì àti pátákó ajúwe** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>ka oríṣiríṣi ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe. b.a:<br>- àdírẹ́sì<br>- Ìpolówó ọjà<br>- ìkìlọ̀<br>- ìtọ́nisọ́nà<br>- ìfòfindè | 1. fífi oríṣiríṣi ohun tí a kọ sí ara pátákó àjúwe hàn<br>2. kíka oríṣiríṣi ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe, b.a<br>- 3, Adéyẹmí way, Garki,Àbújá<br>- máṣe da pàǹtí síbí<br>- yà kóoyọ́, abbl | 1. ṣàfihàn oríṣiríṣi ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe<br>2. Darí kíka oríṣiríṣi ohun tí a kọ sí ara patákó ajúwe tí a fi hàn | 1. wo orísiríṣi ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe tí olùkọ́ fihàn<br>2. kíka oríṣiríṣi ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe tí olùkọ́ fi han | Àtẹ àwòrán ohun tí a kọ sí ara pátákó ajúwe | Ka oríṣiríṣi ohun tí a kọ sí ara pátákò ajú tí ó wà nínú àtẹ àwòrán tí olukó fi hàn |

**KỌ́KỌ̀ ỌRỌ̀:Ẹ̀KỌ́ NÍPA ÀWỌN ÌRỌ́ ÈDÈ YORÙBÁ** **IPELE KẸTA** **APÁ KẸTA**

| **ORÍ ỌRỌ̀** | **ÈRÒŃGBÀ** | **ÀKÓÓNÚ IṢẸ́** | **ÀMÚṢẸ IṢẸ́** | | **OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI** | **ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N** |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | **OLÙKỌ́** | **AKẸ́KỌ̀Ọ́** | | |
| **ẹ̀kọ́ nípa ìparọ́jẹ àti ìsúnkì** | akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. ṣe àlàyé nǹkan tí ìyọ́pọ̀ jẹ́<br>2. kan àwọn ọ̀rọ̀ méjì pọ̀ nípa ìgbésẹ̀ ìyọ́pọ̀ fáwẹ̀lì | Ìyọ́pọ̀ ọ̀rọ̀ méjì<br>b.a<br>-ogún+ọ̀jọ di ọgọ́jọ<br>-ibi+ìjẹ di ibùjẹ<br>-ibi+ ìjókòó di ibùjókòó<br>-ibi+ìgbé di ibùgbé | Kọ àpẹẹrẹ sí ojú pátákó yóò sì ṣe àlàyé ìyọ́pọ̀ fáwẹ̀lì | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ìyọ̀pọ́ fáwẹ̀lì<br>2. sọ àpẹẹrẹ tirẹ̀ | Káàdìbọ́ọ̀dù tí a kọ àpẹẹrẹ sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́ kọ:<br>Àwọn ọ̀rọ̀ mẹ́rin tí a ti ṣe ìyọ́pọ̀ fáwẹ̀lì |

**KỌ́KỌ̀ ỌRỌ̀: ỌRỌ̀- ÈDÈ, ÌDÁNMỌRÁN ÀTI ÀKÀYÉ** **IPELE KẸTA** **APÁ KẸTA**

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Àmì ohùn lórí ọ̀rọ̀ onísílébù kan àti ọlọ́pọ̀ sílébù** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè fi àmì ohùn Yorùbá sí orí ọ̀rọ̀ onísílébù kan àti ọlọ́pọ̀ sílébù bí ó ti yẹ | 1. Àlàyé kíkún lorí oríṣi àmì ohùn Yorùbá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta<br>2. Àwọn lẹ́tà tí ó ń gba àmì ohùn, b.a:<br>- á,a,à<br>- é,e,è<br>3. àmì ohùn lórí ọ̀rọ̀ onísílébù kan, b.a bá,ba,bà<br>4. Àmì ohùn lórí ọ̀rọ̀ onísílébù méjì. B.a:<br>- ọkọ,ọkọ́,ọ̀kọ̀<br>5. àmì ohùn lórí àránmú onísílébù kan, b.a:<br>- kọ̀nkọ̀ | 1. ṣàlàyé lórí oríṣi ohùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta<br>2. kọ àwọn lẹ́tà tó ń gba àmì ohùn<br>3. ṣàlàyé lóri àmì ohùn lórí ọ̀rọ̀ onísílébù kan, méjì,ọlọ́pọ̀ sílebù<br>4. àlàyé lóri àránmúpè onísílébù kan tí ó ń gba àmì lórí<br>5. kọ àpẹẹrẹ lórí orí ọ̀rọ̀ sí ara pátákó fún akẹ́kọ̀ọ́ láti kọ | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ohùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta<br>2. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí lẹ́tà tí ó ń gba àmì ohùn lórí<br>3. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ìlò àmì ohùn lórí ọ̀rọ̀ onísílébù kan, méjìjà ti ọlọ́pọ̀ sílébù<br>4. gbọ́ àlàyé olùkọ́ lórí àrànmúpè onísílébù kan tó ń gba àmì lórí<br>5. kọ ohun tí olùkọ́ kọ sí ara pátákò sínú ìwé | • Káḋíbọ́ọ̀dù tó ń ṣe àfihàn àwọn àmì ohùn lórí fáwẹ̀lì, ọ̀rọ̀ onísílébù kan, méjì àti ọlọ́pọ̀ sílébù<br>• Káàḋì kéékèèké aṣàfihàn àwọn àmì ohù | Kí akẹ́kọ̀ọ́ kọ ọ̀rọ̀ tí olùkọ́ pè fún wọn sílẹ̀, kí wọ́n sì fi àmì sí i bí ó ti yẹ |
| **Ìtẹ̀síwájú lóri àkàyé àti àwon ìbéèrè tí ó tẹ̀lé e** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. Ka ìwé àṣàyàn ní àkàyé<br>2. Dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó súyọ nínú àkàyé | 1. Kíka àyọkà tí a yàn ní àkàyé<br>2. Dídáhùn àwon ìbéèrè tí ó súyọ nínú àkàyé tí a yàn b.a<br>-ìgbéyàwó ní ilẹ̀ Yorùbá<br>-ìsọmọlórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá<br>-aṣọ ilẹ̀ Yorùbá<br>-àwọn ìlú ilẹ̀ Yorùbá<br>-ìtọ́jú ara ẹni | 1. yan àyọkà fún akẹ́kọ̀ọ́<br>2. kíka àyọkà ní àkàyé<br>3. darí dídáhùn àwọn ìbéèrè tí ó jẹyọ nínú àyọkà<br>4. ṣe àlàyé àwọn èdè àmúlò àti ọ̀rọ̀ mìíràn tí ó ta kókó nínú àyọkà | 1. ka àṣàyàn àyọkà ní àkàyé<br>2. dáhùn àwon ìbéèrè tí ó súyọ nínú àyọkà<br>3. tẹ́tí sí àlàyé tí olùkọ́ ṣe lo]rí àwọn ọ̀rọ̀ tí ó jẹ́ èdè àmúlò àti ọ̀rọ̀ mìíràn tí ó ta kókó tí ó súyọ nínú àyọkà | • ìwé àyọkà<br>• àwòrán àwọn ohun tí ó jẹ mọ́ ohun tí ó jẹyọ nínú àyọkà | 1. ka àyọkà lórí ìkíni ní ilẹ̀ Yorùbá<br>2. dáhùn àwon ìbéèrè tí ó súyọ nínú àyọkà lórí ìkíni ní ilẹ̀ Yorùbá |

**KỌ́KỌ̀ ỌRỌ̀: ỌRỌ̀- ÈDÈ, ÌDÁNMỌ̀RÁN ÀTI ÀKÀYÉ** IPELE KẸTA APÁ KẸTA

| ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒǸGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌNI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| **Ìtẹ̀síwájú lórí àkàyé àti àwon ìbéèrè tí ó tẹ̀lé e** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. Ka ìwé àṣàyàn ní àkàyé<br>2. Dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó súyọ nínú àkàyé | 1. Kíka àyọkà tí a yàn ní àkàyé<br>2. Dídáhùn àwon ìbéèrè tí ó súyọ nínú àkàyé tí a yàn, b.a:<br>-ìgbéyàwó ní ilẹ̀ Yorùbá<br>-ìsọmọlórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá<br>- aṣọ ilẹ̀ Yorùbá<br>- àwọn ìlú ilẹ̀ Yorùbá | 1. yan àyọkà fún akẹ́kọ̀ọ́<br>2. kíka àyọkà ní àkàyé<br>3. darí dídáhùn àwọn ìbéèrè tí ó jẹyọ nínú àyọkà<br>4. ṣe àlàyé àwọn èdè àmúlò àti ọ̀rọ̀ mìíràn tí ó ta kókó nínú àyọkà | 1. ka àṣàyàn àyọkà ní àkàyé<br>2. dáhùn àwon ìbéèrè tí ó súyọ nínú àyọkà<br>3. tẹ́tí sí àlàyé tí olùkọ́ ṣe lo]rí àwọn ọ̀rọ̀ tí ó jẹ́ èdè àmúlò àti ọ̀rọ̀ mìíràn tí ó ta kókó tí ó súyọ nínú àyọkà | • ìwé àyọkà<br>• àwòrán àwọn ohun tí ó jẹ mọ́ ohun tí ó jẹyọ nínú àyọkà | 1. ka àyọkà lórí ìkíni ní ilẹ̀ Yorùbá<br>2. dáhùn àwon ìbéèrè tí ó súyọ nínú àyọkà lórí ìkíni ní ilẹ̀ Yorùbá |
| **ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>Dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀dà òye ọ̀rò àyọkà tí a yàn | Ìbéèrè àti ìdáhùn lorí ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ àyọkà tí a yàn | 1. ṣe ìbéèrè lórí ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ àyọkà tí a yàn<br>2. ṣe àmúlò kádìbọ́ọ̀dù tí a kọ ìbéèrè àti ìdáhùn lórí ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ àyọkà sí | Dáhùn Ìbéèrè lórí ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ àyọkà tí a yàn | Kádìbọ́ọ̀dù tí a kọ ìbéèrè àti ìdáhùn lórí ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ àyọkà sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́ dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀dà òye ọ̀rọ̀ àyọkà tí olùkọ́ fún un |
| **Sísọ àyọkà ní sókí** | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>1. sọ oríṣiríṣi àyọkà ní ṣókí<br>2. ṣe àtúnsọ ìtàn inú àwọn àyọkà ní ṣókí<br>3. dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó tẹ̀ lé àyọkà náà | 1. àtúnyẹ̀wọ̀ ìtumọ̀ "ṣókí/ìsọníṣókí"<br>2. yíyan àwọn àyọkà mélòó kan nínú ìn ú àṣàyàn fún kíkà<br>3. kíka àwọn àyọkà náà geere<br>4. ṣíṣe àjíròrò lórí àwon àyọkà náà<br>5. sísọ àwon àyọkà ní ṣókí sókí | 1. ṣe àtúnyẹ̀wò ìtumọ̀ "ṣókí/ ìsọníṣókí"<br>2. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti yan àyọkà mélòó láti inú ìwé àṣàyàn fún kíkà láàyò<br>3. jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ka àwọn àyọkà tí a yàn náà geere<br>4. ṣe ìjíròrò lórí àwon àyọkà náà pẹ̀lú akẹ́kọ̀ọ́<br>5. darí akẹ́kọ̀ọ́ láti lo ìgbésẹ̀ ìsọníṣókí tí a ti kọ́ wọn fi sọ àwọn ìtàn náà ní ṣókí | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí ìtumọ̀ "ṣókí/ìsọníṣókí"<br>2. kópa nínú yíyan àyọkà mélòó kan láti inú ìwé àṣàyàn fún kíkà<br>3. ka àwọn àyọkà tí a yàn náà geere<br>4. kópa nínú ìjíròrò lórí àwon àyọkà náà<br>5. lo àwọn ìgbésẹ̀ ìsoníṣókí tí olùkọ́ kọ́ wọn láti ṣe ìsọníṣókí àwọn ìtàn inú àwọn àyọkà náà | 1. àwòrán tí ó bá èrò inú àwọn àyọkà tí a yàn mu<br>2. káàdì aláfihàn tí a kọ àwọn ọ̀rọ̀ tuntun inú àwọn àyọkà náà sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́ kọ ìtàn tí olùkọ́ sọ fún wọn ní ṣókí sínú ìwé wọn |

KỌ́KỌ̀ Ọ̀RỌ̀: Ọ̀RỌ̀- ÈDÈ, ÌDÁNMỌ̀RÁN ÀTI ÀKÀYÉ IPELE KẸTA APÁ KẸTA

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÒǸGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| Èdè àmúlò | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>Dárúkọ oríṣiríṣi oníṣẹ́ ọwọ́ àti èdè àmúlò wọn | 1. oríṣiríṣi oníṣẹ́ ọwọ́. b.a:<br>- télọ̀/aránṣọ<br>- mẹkáníìkì<br>- onídìrí<br>- káfíntà abbl<br>2. oríṣiríṣi èdè àmúlò àwon oníṣẹ́ ọwọ́ náà b.a télọ̀ – abẹ́rẹ́, òwú ìránṣọ, sísọ̀ọ̀sì, aṣọ, téèpù ìwọ̀nṣọ abbl<br>mẹkáníìkì- jáàkì, òòlù táyà, ẹ́njìnì abbl | 1. ṣe àfihàn àwòrán/fídíò oríṣiríṣi oníṣẹ́ ọwọ́<br>2. sọ oríṣiríṣi èdè àmúlò àwọn oníṣẹ́ ọwọ́ náà<br>3. darí ìjíròrò lórí oríṣiríṣi iṣẹ́ ọwọ́ síwájú sí I àti àmúlò èdè wọn | 1. wo àwòrán fídíò oníṣẹ́ ọwọ́<br>2. tẹ́tí sí oríṣiríṣi èdè àmúlò àwọn oníṣẹ́ ọwọ́ tí olùkọ́ sọ<br>3. kópa nínú ìjíròrò lórí oríṣiríṣi iṣẹ́ ọwọ́ síwájú si àti èdè àmúlò wọn | 1. àwòrán/fídíò<br>2. àtẹ tí akọ oríṣiríṣi iṣẹ́ ọwọ́ sí àti èdè àmúlò wọn | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. dárúkọ oríṣi iṣẹ́ ọwọ́ mẹ́fà tí ó mọ̀<br>2. sọ èdè àmúlò méjìméjì fún iṣẹ́ ọwọ́ méta péré nínú àwọn tí ó dárúkọ |
| Òǹkà Yorùbá | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè: tọ́ka sí àwọn ọ̀rọ̀ tó ṣe pàtàkì fún òǹkà (le, dín, okòó, ọ̀jì, ọ̀rìn) | Títọ́ka sí àwọn ọ̀rọ̀ tó ṣe Pàtàkì fún òǹkà àpẹẹrẹ<br>**i.** **<u>lé</u>** -ẹgbẹ̀sán lé ọgọ́rùn ún = (1900) ókànléláàdọ́ta=(51) mẹ́tàlélọ́gọ́rùn ún =103<br>**ii.** **<u>dín</u>**-igba dín mẹ́sàn án =191 (200-9) Ọ́kàndínlúgba=199 ẹ̀rìndínlógún=16<br>**iii.** **<u>okòó</u>**-okòólélúgba=220<br>**iv.** **<u>ọ̀jì</u>**-ọ̀jìlérúgba= 240 | 1. ka òǹkà tí ó ní àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ṣe pàtàkì sí ara pátákó<br>2. ṣe àlàyé ìlànà tí a fi ń ṣẹ̀dá àwọn òǹkà yìí<br>3. ṣe ìdánrawò fún akẹ́kọ̀ọ́ lórí àwọn ọ̀rọ̀ yìí àti ipa tí wọ́n ń kó nínú òǹkà Yorùbá | 1. da àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ tí a ń lò fún òǹkà yìí kọ sí ara pátákó kọ sínú ìwé rẹ̀<br>2. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́<br>3. ṣe ìdánwò tí olùkọ́ pèsè ní kíláàsì | 1. Káàdíbọ́ọ̀dù<br>2. Káàdì pélébé-pélébé | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. Kọ àwọn òǹkà wọ̀nyí ní èdè Yorùbá<br>- 1600<br>- 1700<br>- 1900<br>- 1500<br>2. Kọ àwon wọ̀nyí ní fígọ̀<br>- Okòólélẹ́gbèrin<br>- Ọ̀jìléléẹ̀dẹ́gbẹ̀ta<br>- ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀sán |

| ORÍ Ọ̀RỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | ÀKÓÓNÚ IṢẸ́ | ÀMÚṢE IṢẸ́ | | OHUN ÈLÒ ÌKỌ́NI | ÌTỌ́NISỌ́NÀ FÚN ÌGBÉLÉWỌ̀N |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | OLÙKỌ́ | AKẸ́KỌ̀Ọ́ | | |
| Orúkọ Yorùbá | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>Sọ oríṣiríṣi orúkọ Yorùbá àti ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ irú orúkọ bẹ́ ẹ̀ | oríṣiríṣi orúkọ Yorùbá àti àlàyé nípa ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ ẹ, àpẹẹrẹ:<br>**i. oríkì**<br>★ Àníkẹ́ ★ Àpèkẹ́<br>★ Àmọ̀pé<br>★ Àkànmú<br>**ii. Ìnagijẹ**<br>★ Jẹ́gẹ́dẹ́<br>★ Owódùnní<br>★ Agùntáṣọ̀ọ́lò<br>**iii. Orúkọ àbíkú**<br>★ Rótìmí ★ Ajá<br>★ Kòkúmọ́<br>★ Ìgbẹ́kọ̀yí<br>★ Dúróoríkẹ̀ẹ́ | 1. pe akẹ́kọ̀ọ́ láti sọ àwọn ìpínsísọ̀rí oríṣiríṣi orúkọ tí wọ́n mọ̀<br>2. kọ àwọn orúkọ náà sí ara pátákó ìkọ̀wé<br>3. pín àwọn orúkọ náà sí ìsọ[rí tí wọ́n bá mu gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe wà lábẹ́ àkóónú iṣẹ́ | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí àwọn orúkọ Yorùbá<br>2. kọ àwọn orúkọ náà ní ìsọ̀rí ìsọ̀rí sí inú ìwé wọn gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ ṣe kọ ọ́ sára pátákó ìkọ̀wé | • pátákó ẹlẹ́mọ̀ọ́<br>• káàdì pélébé-pélébé tí a kọ àwọn orùkọ Yorùbá sí | Kí akẹ́kọ̀ọ́:<br>1. sọ ìpínsísọ̀rí àwọn orúkọ tí Yorùbá ń jẹ́<br>2. sọ ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ irú orúkọ bẹ́ ẹ̀<br>3. ṣe ìwádìí àwọn orúkọ mìíràn bọ̀ láti ilé |
| Ìsọ̀ri ọ̀rọ̀<br><br>(ìtẹ̀síwájú) | Akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>ṣe àlàyé kíkún àti àpẹẹrẹ lórí<br>1. ọ̀rọ̀ atọ́kùn<br>2. ọ̀rọ̀ asopọ̀ | Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀<br>1. ọ̀rọ̀ atọ́kùn<br>2. ọ̀rọ̀ asopọ̀ | kọ àpẹẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀ tí ó lè wà lábẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan àpẹẹrẹ<br>i. ọ̀rọ̀ atọ́kùn sí, ní,fi,ti<br>ii. ọ̀rọ̀ asopọ̀ ṣùgbọ́n, àti,àmọ́ | 1. tẹ́tí sí àlàyé olùkọ́ lórí sọ̀rí kọ̀ọ̀kan<br>2. kọ àwọn àpẹẹrẹ tí olùkọ́ kọ sókè<br>3. pe àwọn ọ̀rọ̀ náà bí olùkọ́ ṣe pè é fún wọn | Káďibọ́ọ̀dù àti<br><br>Káàdì pélébé-pélébé | Kí akẹ́kọ̀ọ́ tọ́ka sí irúfẹ́ ọ̀rọ̀ tí ó wà lábẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan nínú gbólóhùn kéékèèkéé tí olùkọ́ kọ sójú pátákó |

**Participants List**

| Project Coordinating Team | | | |
|---|---|---|---|
| **S/NO** | **NAME** | **Role** | **Institution** |
| 1. | Professor Ismail Junaidu | Project Coordinator | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda-Abuja |
| 2 | Dr. Garba Dahiru Gandu | Project Manager | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda-Abuja |
| 3 | Dr. Chima Jonas Egbujuo | Project Technical Facilitator | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda-Abuja |

| Yoruba curriculum Technical Team | | |
|---|---|---|
| **S/N** | **Name** | **Institution** |
| 1 | Professor Harrison Adeniyi | Lagos State University, Lagos |
| 2 | Dr. Babalola Victoria Olubanwo | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC), Sheda-Abuja |
| 3 | Professor Philip Ogundeji Adetutu | University of Ibadan, Ibadan |
| 4 | Dr. Adesuyan Raphael Ayodeji | Adeyemi College of Education, Ondo |
| 5 | Mrs. Mary Owoduni | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC) Model School, Sheda-Abuja |

| Plenary Technical Team | | |
|---|---|---|
| **S/N** | **Name** | **Institution** |
| 1 | Professor Zephinus Njoku | University of Nigeria, Nsukka |
| 2 | Prof. Chinyere Ogbuanya | University of Nigeria, Nsukka |
| 3 | Dr. Grace Ajagun | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC), Sheda-Abuja |
| 45 | Prof. Mariam A. Suleiman | Ahmadu Bello University, Zaria |
| 6 | Mrs. Hadiza Nasir Wali | Borno State Ministry of Education, Maiduguri |
| 7 | Mr. Bala Mari Tatama | National Commission for Mass Literacy, Adult and Non-formal Education (NMEC) ABUJA |
| 8 | Dr. Nneji Godfrey | Federal College of Education (Technical), Yaba, Lagos |
| 9 | Mr. Nura G. Garba | Medile Primary School Kumbotso, Kano |
| 10 | Mr. Lawal Yahaya | Government Senior Secondary School, Dutsinma Katsina |
| 11 | Dr. Eleri Nnanna | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC), Sheda-Abuja |
| 12 | Mr. Mu'azu Mamuda | Government Secondary School, Kaita, Katsina |
| 13 | Dr. David Kolawole Omole | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC), Sheda-Abuja |
| 14 | Professor Uzoechi Beneath Coleman | Nasarawa State University, Keffi |
| 15 | Dr. Fidelis Egbe | Veritas University, Keffi |
| 16 | Dr. Judith kanu | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC), Sheda-Abuja |
| 17 | Professor Garba Sa'ad | Bayero University, Kano |
| 18 | Rabiu Garba | Government Junior Secondary School, Garko Dausai, Kano |
| 19 | Dr. Mohammed Tukur Usman | FCT College of Education Zuba |

| | | |
|---|---|---|
| 20 | Dr. Bokolo Mabel | Model Primary School. Yenagoa, Bayelsa |
| 21 | Dr. Hassan Musa Gusau | National Commission for Mass Literacy, Adult and Non -formal Education (NMEC) ABUJA |
| 22 | Ms.Abiola Sanusi | Riplington Education Initiative (REI), Abuja |
| 23 | Womboh i. Michael | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC), Model School, Sheda-Abuja |
| 24 | Bello Mushood | FCT College of Education Zuba |
| 25 | Habib Ahmed Jibrin | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC), Sheda-Abuja |
| 26 | Abdulkadir Yusuf | Government Senior Secondary School, Abukur, Rimi, Katsina |
| 27 | Professor M. D. Suleiman | Bayero University, kano |
| 28 | Dr. Gloria Ngozi Ugbor | University of Nigeria, Nuskka |
| 29 | Dr. Nkechi Adiele | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda -Abuja |
| 30 | Mrs. Okoro-Opara Anthonia | FCT Education Resource Centre, Abuja |
| 31 | Dr. Nnabuihe Chigozie Bright | University of Lagos, Lagos |
| 32 | Mr. Ogbonna Chidi | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC) Model School, Sheda-Abuja |
| 33 | Professor Ahmed Amfani | Usman Danfodio University. Sokoto |
| 34 | Mr. Ibrahim Mohammed Gandu | Kano State College of Education, Kano |
| 35 | Mr. Salisu Ibrahim | G.G.D.S.S Rafindadi, Katsina State |
| 36 | Mr. Babagana Gartimari | Borno SUBEB |
| 37 | Mrs. Amina Ibrahim Abubakar | Abubakar Tatari Ali Polytechnic, Bauchi |
| 38 | Mr. Almustapha Sambo | Usman Danfodio University. Sokoto |
| 39 | Professor Mamma Musa | Ahmadu Bello University, Zaria |
| 40 | Dr. Nnaji N. Lambert | Alvan Ikoku Federal College of Education, Owerri |
| 41 | Mr. Ibrahim Salaudeen | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC) Model School, Sheda-Abuja |
| 42 | Mr. Famade Oladiran | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda -Abuja |
| 43 | Mr. Lawal Ashura | S.U.N.C.A.I.S, Katsina State Ministry of Education |
| 44 | Professor Ibrahim Galadima | Usman Danfodio University. Sokoto |
| 45 | Dr. Akinsola Olakunle S. | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda -Abuja |
| 46 | Dr. Ighalo Odiagbe | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda -Abuja |
| 47 | Mr. Ibrahim Yahaya El-Ladan | Federal College of Education, Zaria |
| 48 | Professor Kayode Omole | University of Abuja |
| 49 | Dr. Eva Kyaagba | Society for Gender and Child Advancement, Abuja |
| 50 | Dr. Imaobong Nsehe | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda -Abuja |
| 51 | Dr. Mikailu Ibrahim | FHI 360 |
| 52 | Dr. Lawani Margaret | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda -Abuja |
| 53 | Professor Ismaila Tsiga | Centre for Reading Research and Development, Bayero University, Kano |
| 54 | Dr. Bernie Ikegulu | Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC). Sheda -Abuja |
| 55 | Mr. Jacob Masanso | Save the Children International, Abuja Office |
| 56 | Mr. Onisimus Laban | Plan International, Abuja Office |